**ONDO JOURNAL OF ARTS**
**Faculty of Arts**
**Adeyemi Federal University of Education, Ondo**
OPEN ACCESS https://ojaafued.com/index.php/ojall **Volume 1, Number *1, 2025***

# Ìtúpalẹ̀ Àṣàyàn Àkóónú Oríkì Ilẹ̀ Yorùbá

**Ìlúfóyè Fáwọlé ÒJÓ, PhD**
**Àti**
**Mercy Ayọ̀ FASEHUN, PhD**

**Department of Yorùbá,**
**Faculty of Arts,**
**Adéyẹmí Federal University of Education, Oǹdó**
ilufoyeojo@gmail.com
08037272440

**Àṣamọ̀**

*Oríkì jẹ́ ẹ̀yà lítíréṣọ̀ kan tí ó jinlẹ̀ púpọ nínú gbogbo lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá nítorí pé ó jẹ́ orísun ìtàn, ẹ̀sìn, ìṣe, ìṣesí, ìfẹ́, èèwọ̀, iṣẹ́ ìran, àbùdá ìrísí àti ìwà ìran kan. Yàtọ̀ sí èyí, oríkì kò mọ ní ti ẹ̀dá ènìyàn nìkan, Olódùmarè, àwọn òrìṣà àkúnlẹ̀bọ, àwọn ẹranko àti ẹyẹ náà ní oríkì tiwọn. Àwọn nǹkan mìíràn bí kòkòrò, òkè, ilẹ̀, odò, igi, ewé, àwọn oúnjẹ ìbílẹ̀, èso, àìsàn, àrùn àti àwọn nǹkan mìíràn náà ní oríkì tiwọn lọ́kan-ò-jọ̀kan. Èyí fi hàn wá pé oríkì gbòòrò púpọ̀ àti pé kò fẹ́rẹ̀ sí ohun tí ó wà lórílẹ̀ ayé yìí tí Olódùmarè dá tí kò ní oríkì tirẹ̀. Oríkì, pàápàá oríkì orìlẹ̀ máa ń farahàn nínú gbogbo ìṣèré àwọn akéwì tàbí apohùn Yorùbá. Ìṣàmúlò oríkì nínú ìṣèré wọn máa ń fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí akéwì tó dáńtọ́ láwùjọ Yorùbá. Nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí, a wo ìtumọ̀ àti àbùdá oríkì Yorùbá. A tún ṣe ìtúpalẹ̀ àkóónú àṣàyàn oríkì tí ó tọ́ka sí àṣá, ẹ̀sìn, ìṣe, èèwọ̀, ìtàn, ẹbí ohun tí ó jẹ́ àléébù àwọn ìran wọ̀nyí. Àbájáde iṣẹ́ ìwádìí yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé oríkì máa ń roni, àlàjẹ́ a sì máa ro ènìyàn. Oríkì a máa mù orí ẹni wú, ó máa fúnni ní ìgboyà pẹ̀lú ìmọ̀lára, ó máa ń júwe orírun ẹni, ó sì máa ń fini lọ́kànbalẹ̀ pé ojúlówó ọmọ ìran báyìí ni irú ẹni bẹ́ẹ̀ jẹ́. Ọ̀kan lára àwọn ogún ìní ìran kọ̀ọ̀kan ní ilẹ̀ Yorùbá ni oríkì jẹ́, a kò gbọdọ̀ jẹ́ kí ó parun.*

**Ìfáárà**

Ẹ̀yà lítíréṣọ̀ kan tó jinlẹ̀ ni oríkì nítorí pé ó jẹ́ orísun ìtàn, ìwà, ìfẹ́, èèwọ̀, iṣẹ́ ìran, àbùdá ìrísí àti ìwà ìran kan. Yàtọ̀ sí èyí, oríkì kò mọ ní ti ẹ̀dá ènìyàn nìkan, Olódùmarè, àwọn òrìṣà àkúnlẹ̀bọ, àwọn ẹranko, bí òkété, ẹtu, erin, kìnnìún, túùpú àti ẹyẹ bí àparò, ẹtù àti ọ̀kín náà ní oríkì tiwọn. Àwọn ẹ̀dá Ọlọ́run mìíràn bí kòkòrò náà ní oríkì tiwọn láàyè ọ̀tọ̀. Bákan náà ni òkè, ilẹ̀, odò, igi, ewé àti àwọn oúnjẹ ìbílẹ̀ bí iyán, àmàlà àti ẹ̀bà ní oríkì. Àwọn ohun mímu bí omi, ẹmu àti ọtí líle (ògógóró) náà ní oríkì pẹ̀lú. Àwọn èso bí ọsàn, ìbẹ́pẹ àti òro náà ní oríkì bákan náà. Àìsàn, àrùn àti àwọn nǹkan mìíràn náà ní oríkì tiwọn lọ́kan-ò-jọ̀kan. Èyí fi hàn wá pé oríkì gbòòrò púpọ̀ àti pé kò fẹ́rẹ̀ sí ohun tí ó wà lórílẹ̀ ayé yìí tí Olódùmarè dá tí kò ní oríkì tirẹ̀ láwùjọ Yorùbá.

Oríkì èyí tí ó jẹ wá lógún nínú iṣẹ́ yìí ni èyí tí ó jẹ mọ́ ènìyàn. Abala èyí tí ó sì jẹ mọ́ orí-ọ̀rọ̀ yìí ni oríkì orílẹ̀ Yorùbá. Àwọn àṣàyàn oríkì orílẹ̀ Ẹ̀ṣọ́-Ìkọ̀yí, Arẹ̀ṣà, Ológbìn-ín, Olúòjé, Olúfọ́n, Ewú Ìwínrin, Ìrènímògún, Àágberí, Alápà àti ọmọ Olókùn-ẹṣin ni a ó fi ṣe ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ yìí. A ṣe èyí láti lè ṣe àfàyọ ọpọ àwọn àkóónú tí ó wà nínú oríkì orílẹ̀ Yorùbá. Bí a bá ki orìki ìran ẹni dáadáa, kì í délẹ̀délẹ̀ tàbí délédélé, ó di dandan kí orí irú ẹni bẹ́ẹ̀ wú pàápàá tí kì í bá ṣe ọmọ àlè ìran náa. Ohun tí ó ń wúni lórí nínú oríkì yìí gan-an ni orírun ẹni. Èyí fi hàn pé kò sí ìran Yorùbá kan tí kò ní orírun tirẹ̀. Kíki orírun ìran kan nípa agbára ìran bẹ́ẹ̀, iṣẹ́ wọn, ìṣe wọn, iṣẹ́ tí wọn ń ṣe àti ìhùwàsí wọn délédélé ló máa mú kí orí ènìyàn ó wú nígbà tí àwọn apohùn bá ń ki oríkì orírun rẹ̀. Orílẹ̀ ní ṣe pẹ̀lú ẹ̀yà ibi tí ẹnìkọ̀ọ̀kan ti wá àti orílẹ̀ ilẹ̀ tí a bí ni sí. Orí ilẹ̀ tí a bí ènìyàn sí yìí pẹ̀lú oríkì rẹ̀ ni ó parapọ̀ di oríkì orílẹ̀.

**Oríkì Orílẹ̀**

Ọ̀kan lára àṣà Yorùbá ni kíki oríkì ọmọ àti orílẹ̀ rẹ̀ láwùjọ Yorùbá. Àṣà yìí kò sì ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn rárá. Àwọn onímọ̀ ìṣáájú bíi Gbàdàmọ́sí (1961), Babalọlá (1966, 2000); Ọlátúnjí (1978); Adéoyè (1982); Àmàó (1989); Ọdẹàjọ̀ (1992); Dáramọ́lá àti Jéjé (1995), Rájí; Adéọlá; Òjó; Táíwò àti Àjùwọ̀n (2009) àti àwọn onímọ̀ mìíràn bí Akínyẹmí (1991); Oyèláràn (2014); Barber (1979); Àjàyí (2016); Àjùwọn (2017); Ademuyiwa (2022); Òjó (2022) ati Oyèwẹ̀sọ̀ (2025) ti ṣiṣẹ́

lórí oríkì. Àwọn kan ṣiṣẹ́ lórí oríkì orúkọ, oríkì ìnagijẹ, oríkì ìlú, oríkì àwọn akọni, oríkì ẹranko nígbà tí àwọn kan sì ṣiṣẹ́ lórí àkójọpọ̀ oríkì orílẹ̀. Àkíyèsí fi hàn pé kò sí àṣàdànù nínú gbogbo ohun tí wọ́n ti sọ nípa oríkì, ìwúlò rẹ̀ àti ìlò rẹ̀ láwùjọ Yorùbá.

Oríkì ni irúfẹ́ ọ̀nà tí àwọn Yorùbá fi máa ń pọ́n ara wọn lé, tí wọ́n sì tún fi í fìyìn fún ara wọn yálà ní tààrà tàbí ní ìlànà ewì (Ọdẹàjò, 1992). Oríkì tún jẹ́ àwọn ọ̀rọ̀ ìṣírí tí àwọn Yorùbá máa ń fi ṣe àpọ́nlé ara wọn tàbí ẹni tí inú wọn dùn sí. Àṣà yìí ni a fi ń ránnilétí ohun rere tí onítọ̀hún ti ṣe tàbí láti fi han ènìyàn nígbà mìíràn pé inú wa dùn sí olúwarẹ̀. Bí ènìyàn bá ń ṣe iṣẹ́ tàbí tí ó ń jó lójú agbo, bí ó bá gbọ́ oríkì rẹ̀, ara rẹ̀ á yá gágá á sì múra sí ohun tí ó bá ń ṣe nígbà náà dáadáa. Oríṣi ọ̀nà ni a lè ki ènìyàn sí. Bí àpẹẹrẹ, a lè ki ènìyàn sí ìdílé, ìran, ìlú, ìrísí tàbí ipò rẹ̀ láwujọ. À ń ki ọba bí ilé àti agbára rẹ̀ bá ti ṣe tó, a sì lè kì í sí ọwọ́ tí ó bá yọ nígbà tí ó bá gun orí oyè tàbí ìtẹ́ tán, bákan náà ni a lè ki àwọn jagunjagun, àwọn ìyàmi àti àwọn alágbára ayé láti lè fi pọ́n wọn lé tàbí kan sáárá sí wọn kí wọn ó lè baà yọ́nú sí wa. Irú ọ̀rọ̀ tàbí ayọ̀ ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ tí ó ṣúyọ nínú orúkọ ènìyàn, tàbí iṣẹ́ rẹ̀ là ń pè ní oríkì.

Johnson (1966:87) tí Oyèláràn (2014:158-165) mú lò sọ pé:

> When the orúkọ (name) the oríkì (attributive) and the orílẹ̀ (totem) are given, the individual becomes distinctive, the family is known, and he can at any time be traced... Two men may be found with the same name, but rarely with the same cognomen together and more rarely still with the same totem as well. The man is usually known by his orúkọ (name) (familiarity by his oríkì (attributive). The oríkì is always used in conjunction with his orílẹ̀ (the family stock or totem) expressed or understood always expressed.
>
> Nígbà tí a bá sọ orúkọ, oríkì àti orílẹ̀ náà á tèlé e, èyí ni yóò ya ẹnìkọ̀ọ̀kan sọ́tọ̀ tí a ó fi mọ ìdílé rẹ̀ àti pé a ó lè tọpasẹ̀ ibi tí ó ti wá. Ènìyàn méjì lè dìjọ máa jẹ́ orúkọ kan náà ṣùgbọ́n ó ṣòro díẹ̀ kí wọ́n tó lè máa jẹ́ oríkì papọ̀, bẹ́ẹ̀ ló sì tún ṣòro kí wọ́n dìjọ máa jẹ́ orílẹ̀ kan náà. A máa ń dá ènìyàn mọ̀ pẹ̀lú orúkọ, dáa mọ̀ pẹ̀lú oríkì. A máa ń kan oríkì pọ̀ mọ́ orílẹ̀ ni nígbà tí a bá ń ki onítọ̀hún.

Bí a bá tẹ̀lé èrò Johnson (1966) yìí, a lè sọ pé Adéwálé gẹ́gẹ́ bí orúkọ pọ̀ láyé ṣùgbọ́n bí ó bá ti di Adéwálé Àrẹ̀mú Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí, ọmọ ẹrú Ọ̀fà, ó ti yàtọ̀ sí Adéwálé mìíràn tí a kò kì báyìí. Adéwálé jẹ́

(orúkọ), Àrẹ̀mú jẹ́ (oríkì) nígbà tí Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí sì jẹ́ orílẹ̀ rẹ̀. Ìdí nìyí tí Oyèláràn (2014) fi sọ pé bí nọ́ńbà ti ṣe jẹ́ sí àwọn Amẹ́ríkà, tí ó sì jẹ́ pé bí ó bá ti mọ nọ́ńbà ìdáàbòbò ajẹmáwùjọ (social security number) ènìyàn, tí o sì mọ nọ́ńbà láńṣẹ̀ẹ̀sì àti ti tẹlifóònù rẹ̀, o ti mọ̀ ọ́n tán, bẹ́ẹ̀ náà sì ni orúkọ oríkì àti orílẹ̀ jẹ́ láàrin àwọn Yorùbá. Èyí fi hàn pé nọ́ńba idánimọ̀ láwùjọ ni oríkì ènìyàn náà jẹ́.

Babalọlá (1967) nínú Oyèláràn (2014) gbà pé ìyàtọ̀ díẹ̀ wà láàrin oríkì àti orílẹ̀. Babalọlá (1967) tẹ̀síwájú pé orílẹ̀ ènìyàn láàrin àwọn Yorùbá ni àpapọ̀ àwọn babańlá àti ìyáńlá tí ó ti wà ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ìtàn ìdílé olúwarẹ̀. Oríkì orílẹ̀ jẹ́ orúkọ jáǹtirẹrẹ tó júwe ìwà, ìṣe àti àrà àwọn babańlá àti ìyáńlá tí à ń sọ̀rọ̀ bá wọ̀nyí yóò lọ sẹ́yìn ayé àtijọ́ gan-an kété lẹ́yìn tí Ọ̀ràn-án-yàn tẹ Ọ̀yọ́-ilé dó. Ìtumọ̀ tí Babalọlá fún oríkì yìí ń fẹ́ àtúnyẹ̀wò. Ìdí ni pé àkóónú oríkì orílẹ̀ kún ju èyí tí Babalọlá tọ́ka sí lọ. Oríkì orílẹ̀ kẹnú púpọ̀ nítorí pé ó máa ń júwe ìwà, ìṣe, àrà, èèwọ̀, àbùdá ìrísí, iṣẹ́ ìran/ìdílé àti àléébù tí a mọ irú ìran bẹ́ẹ̀ mọ́. Ohun tí Abólúbọ̀dé (1961) sọ ní tirẹ̀ ni pé oríkì ni ọ̀rọ̀ tí a kójọ láti fi yin ènìyàn, ẹranko, ìlú, oúnjẹ pẹ̀lú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn òrìṣà, ohun mìíràn tí a kò lè dárúkọ wọn tán; yálà ohun náà wà láàyè ni tàbí ó ti kú. Nípa báyìí, oríkì ohun tàbí ẹni tí à ń kì ni yóò fi gbogbo àwọn ìgbésí-ayé rẹ̀ hanni, kì baà ṣe akíkanjú, ọlọ́gbọ́n ẹ̀wẹ́ tàbí asorun iwájú pọ̀ mọ́ tìpàkọ́.

Ẹ̀wẹ̀, Láṣebìkan (1958:32) náà sọ pé:

> Oríkì ni ìsọ ibi tí enia tiṣẹ̀, bí nwọ́n ti l’ágbára tó ní ìdílé wọn, bí nwọ́n ti là tó, àti oríṣiríṣi nkan akọni tí nwọ́n ti ṣe gbogbo.

Beier àti Gbàdàmọ́sí (1959:12) ki oríkì báyìí pé “oríkì is a poetic phrase that is used to describe or praise” (oríkì ni ewì kúkúrú tí à ń lò láti fi ṣàpèjúwe tàbí yin nǹkan). Bí a bá wo àlàyé tí àwọn onímọ̀ ti fún oríkì àti oríkì tí ẹnìkọ̀ọ̀kan ti fún un a ó rí i pé igbó kan náà ni ọdẹ gbogbo wọn ń dẹ, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èrò tí ẹnìkọ̀ọ̀kan ní lórí oríkì àti orílẹ̀ kún ju ara wọn lọ. Àrẹ̀mú (1979) ṣàlàyé pé nínú àkójọpọ̀ oríkì náà ni a ti rí i pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn ẹranko ló ní oríkì orílẹ̀, tí àwọn oríkì orílẹ̀ náà sì jọ ti àwọn Yorùbá-ìṣènìyàn ìṣẹranko! Nínú àwọn oríkì yìí ni a ti tún rí àpèjúwe bí àwọn ẹ̀dá ẹlẹ́mìí kéékèèké wọ̀nyí ti rí, ìṣesí wọn, oúnjẹ wọn, iṣẹ́ ìbílẹ̀ wọn, àti ìwúlò wọn fún ènìyàn. Èyí fi hàn pé gbogbo ohun ti Olódùmarè dá pátá ni ó ní oríkì tirẹ̀ láàyè ọ̀tọ̀. Òjó (2022) náà ṣiṣẹ́ lórí àfihàn ẹ̀dá Òjó nínú oríkì Yorùbá. Ìṣàfihàn àmúyẹ àti àléébù tí ó wà nínú oríkì ẹ̀dá Òjó tí ó jẹ́

**ONDO JOURNAL OF ARTS**
**Faculty of Arts**
**Adeyemi Federal University of Education, Ondo**
OPEN ACCESS https://ojaafued.com/index.php/ojall **Volume 1, Number *1, 2025***

ọ̀kan lára orúkọ àmútẹ̀rùnwá Yorùbá ni ó ṣe nínú ìtúpalẹ̀ oríkì rẹ̀. Àbájáde iṣẹ́ ìwádìí lórí oríkì jẹ́ kì á mọ̀ pé oríkì a máa ro ènìyàn nítorí pé ó máa ń fi ìṣesí àti ìhùwàsí ẹ̀dá hàn.

Ní èrò tiwa, a lè sọ pé ajúwe ìwà, ìṣe, àṣà, ilẹ̀ àti àbùdá ẹni ni oríkì jẹ́. A lè fi oríkì ṣàpọ́nlé ènìyàn tàbí nǹkankan. A lè fi júwe ènìyàn, a sì lè lò ó láti fi ẹnu àbùkù kàn án pẹ̀lú. Oríkì a máa wú àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ayé àtijọ́ jáde. Ìjẹyọ ọmọ, ẹni, ọkọ, ará, ìyekan àti ìbátan la fi ń dá oríkì mọ̀. Èrò tiwa nípa ìtumọ̀ oríkì yìí wà ní ìbámu pẹ̀lú ìwádìí tí a ṣe láti ẹnu Àyánkọ́ṣọ̀ọ́ Àyángúnjú ní agbo ilé Alubàtá àti Ọlọ́jẹ̀ẹ̀dé Oyèdùntán ní agbo ilé Mérinmẹ́fọ̀n, Ọ̀là-Èjìgbò ní 20/06/2018.

Àkíyèsí mìíràn tí a tún ṣe sí oríkì ni pé a lè fi ki ènìyàn sí ìdílé ibi tí a ti bí i. Bí àpẹẹrẹ, bí ó bá jẹ́ ọmọ ìdílé Eléégún tàbí ìdílé Ọlọ́sanyìn. A tún lè ki oríkì àbísọ ọmọ ẹni bí ó bá jí ní òwúrọ̀ kùtùkùtù láti lọ kí òbí rẹ̀. A lè ki oríkì ọmọ bẹ́ẹ̀ láti fi dá a láraya tàbí wú u lórí bí ó bá wùwà kan tí ó dára tàbí fakọ yọ nínú ìṣe kan. A lè lo oríkì láti lè fi kan sáárá sí ẹni tí ó bá ṣe nǹkan rere nílé ayé tàbí tí ó ń ṣe nǹkan ayọ̀ bí ìgbéyàwó, ayẹyẹ ìsìnkú àgbà, ìṣílé àti ìyọra. Nítorí náà, bí a ti ń ki ènìyàn sí orúkọ, ìdílé, bẹ́ẹ̀ náà ni a ń ki ènìyàn sí ìlú. Kíki ènìyàn sí ìlú rẹ̀ yìí là ń pè ní orílẹ̀. Èyí sì yàtọ̀ díẹ̀ sí oríkì. Gbogbo ènìyàn tí a bá rí láàrin ìlú yìí la ó kì bákan náà. Kò sí ìdílé tí a kò lè kì bẹ́ẹ̀, èyí gan-an ni ó ń jẹ́ orílẹ̀.

**Oríṣì Oríkì**

Oríṣìíríṣìí oríkì ló wà. Ọdẹàjò (1992: 9-33) pín oríkì sí àwọn ọ̀nà wọ̀nyí: Bí àpẹẹrẹ oríkì àbísọ, oríkì orírun, oríkì orílẹ̀, oríkì ìdílé, oríkì ìlú, oríkì orúkọ àmútọ̀runwá àti oríkì bọ̀rọ̀kìnní.

- Oríkì orúkọ àbísọ ni Ìṣọ̀lá, Àmàó, Àdìgún, Àṣàkẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Oríkì ìlú ni Ìbàdàn, Ìgbàjà, Ọ̀là, Àkúrẹ́, Oǹdó, Ìkọ̀lé, Ìwó, Ọ̀yọ́, Ilé-Ifẹ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Oríkì ìdílé ni Olúpo, Olúgbọ́n, Òòré àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Oríkì orúkọ àmútọ̀runwá ni Ìgè, Òjó, Àjàyí, Àìná, Ìbejì, Ìlọ̀rí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Oríkì bọ̀rọ̀kìnní ni Ọ̀pẹ́lẹ́ngé, kọ́rọ́bọ́tọ́ bí ọká, Ṣọ̀bọ̀rọ́yẹjú, Agùntáṣọ̀ọ́lò, Eyíngóòlù, Ìbàdíàrán, Ẹlẹ́yinjú-ẹgé, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.
- Oríkì àwọn òrìṣà ni Ṣàngó Olúkòso, Ògún Lákáayé Ọsìn-mọlẹ̀, Ifá Olókun Asọ̀rọ̀dayọ̀, Ọ̀sanyìn Onímegbò ọ̀nà Ìráyè, ó gbọ̀pá ọwọ́ ọlọ́kùnrùn sọnù, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ (Ọlátúnjí, 1984: 67-73).

Oyèláràn (2014: 161-168) ní tirẹ̀ pín oríkì sí àwọn ọ̀nà wọ̀nyí (mẹ́ta):

**Oríkì àdáj̣é tàbí oríkì àbísọ:** Èyí nìkan ni Gbàdàmọ́sí (1961); Johnson (1966); Ọláyọmí (1968) àti Adéoyè (1982) tọ́ka sí. Oríkì àdájẹ́ fún ọkùnrin ni Àkànbí, Ìṣọ̀lá, Àdìó, Ayànó nígbà tí Àbẹ̀ní, Àṣàké, Àṣàkún, Àwẹ̀ró, Àwẹ̀ní àti Àbẹ̀bí sì jẹ́ àpẹẹrẹ oríkì àdájẹ́ fún obìnrin.

**Oríkì Àlàjẹ́:** Èyí ni àdàpè orúkọ tí a fún ẹni tí ó jẹ́ orúkọ kan rí, tí a wá ń fi pe gbogbo ẹni tó bá tún ń jẹ́ orúkọ yẹn lẹ́yìn rẹ̀. Ó lè jẹ́ ìtorí ìwà ẹni àkọ́kọ́ tàbí bí ó ṣe rí tàbí nítorí ìṣe rẹ̀ ni wọ́n ṣe fún ẹni náà ní àdàpè yẹn. Ó dàbí ẹni pé orúkọ ẹ̀fẹ̀ tàbí ìnagijẹ ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ àlàjẹ́ sábà máa ń bẹ̀rẹ̀. Ó sì ní irú ohun tí ẹni bẹ́ẹ̀ ṣe kí á tó panupọ̀ pè é bẹ́ẹ̀, bí i ti àpẹẹrẹ Adéyẹmí tí a kì ní "Alówólódù bí Ìyere". Ìnagijẹ ni, bí àdàpè tí ó ń tọ́ka ìṣe, ìwà tàbí ìwò bí mériìírí tí a mọ̀ mọ́ ẹni. Ó lè jẹ́ ohun àbùkù bí ti ìnagijẹ ẹlòmíràn tàbí ohun ẹwù bí àdàpè tí àwọn obìnrin-ilé ń fún àwọn ọmọdé tí wọ́n bá bá nílé ọkọ tí wọn kò sì gbọdọ̀ pè wọ́n lórúkọ. Bí àpẹẹrẹ,

Ayíluk̀ọ = ọmọbìnrin tí ó lómira.
Àtàrí-ò-jóòrùn-ó-ràn = ọmọ tí orí rẹ̀ tóbi.
Ọ̀pẹ́lẹ́ngé = ọmọ tí kò sanran, tí ó tín-ín-rín.

Bí ó bá jẹ́ Àjàyí, gbogbo ẹni tí ó ń jẹ́ bẹ́ẹ̀ ni à ń dàpè ní:

- Oníkànga àjípọn
- Ò-bomi-òsùùrù-wẹdà.

**Oríkì orílẹ̀**: Oríṣi oríkì mẹ́ta ni Oyèláràn (2014) gbà pé ó wà. Àkọ́kọ́ ni oríkì àdájẹ́ tàbí oríkì àbísọ. Èkejì ni alálàjẹ́. Ẹ̀kẹta ni oríkì orílẹ̀. Orílẹ̀ ènìyàn ni àpapọ̀ àwọn babańlá àti àwọn ìyáńlá tí ó ti wà láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ ìtàn ìdílé olúwarẹ̀. Oríkì orílẹ̀ sì jẹ́ oríkì, oríkì jańtirẹrẹ tí ó júwe ìwà, ìṣe àti àrà àwọn babańlá àti ìyáńlá (Babalọlá, 1967). Bí àpẹẹrẹ, oríkì ìran Ajíbógundé, ìran Ọlọ́fà, ìran Olúòjé, ìran Olúkòyí, ìran Ẹ̀ṣà-Ògbín, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ohun tí a ṣe àkíyèsí nípa ìpínsísọ̀rí oríkì orílẹ̀ tí Oyèláràn (2014) ṣe ni pé kò fi bẹ́ẹ̀ yàtọ̀ sí ìpínsísọ̀rí oríkì tí Babalọlá (1967) ṣe. Àfikún àlàyé nípa oríkì orílẹ̀ ni Oyèláràn ṣe nínú iṣẹ́ tirẹ̀.

## Àyẹ̀wò Àṣàyàn Oríkì Orílẹ̀ Yorùbá

Onírúurú nǹkan ni a máa ń bá pàdé nínú oríkì-orílẹ̀ Yorùbá. Nínu oríkì orílẹ̀ ti ṣàyàn-oríkì Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí, Arẹ̀ṣà, Ológbìn-ín, Olúòjé, Olúfọ́n, Ewú Ìwínrín, Ìrènímìgún, Àágberí, Alápà àti Ọmọ Olókùn-Ẹṣin nìkan ni a fẹ́ yẹ̀ wò nínú iṣẹ́ yìí. Lára àpẹẹrẹ àwọn ohun tí a máa ń bá pàdé nínú oríkì-orílẹ̀ Yorùbá nìwọ̀nyí: Iṣẹ́ ìran, èèwọ̀, ẹ̀sìn, ìṣesí àti ìhùwàsí, ìbátan, ìtàn sísọ/ìyán-ọ̀rọ̀-fẹ́ẹ́rẹ́, àpèjúwe, ìrísí, ìwà ọ̀falè, ìwà ṣekárími, ìwà akíkanjú, ìwà ìmọ́tótó àti ibùdó ìran.

**Iṣẹ́ Ìran**

Oríkì orílẹ̀ máa ń ṣe àfihàn iṣẹ́ ìran kan. Bí àpẹẹrẹ, nínú oríkì-orílẹ̀ ìran Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí/Oníkòyí ni a ti mọ̀ pé iṣẹ́ ogun jíjà ni iṣẹ́ babańlá wọn láyé àtijọ́. Àwọn Yorùbá gbà pé àwọn ọmọ Oníkòyí já sí ọmọ Ẹ̀ṣọ́. Ìdí nìyí tí akọni fi pọ̀ láàrin wọn. Gẹ́gẹ́ bí jagunjagun, wọ́n máa ń jẹ́ akíkanjú, wọ́n máa ń láyà bẹ́ẹ̀ sì ni wọ́n tún máa ń lágídí pẹ̀lú. Àyọlò inú oríkì ìran Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí kan fi èyí hàn báyìí pé:

Ọmọ Olúkòyí Mògbó
Ọmọ Aṣíjú-apó-pìrí
Dagba ọfọ̀ sọ́fun
A-pọ̀fun-yọ̀yọ̀ da igba ọfà sílẹ̀
Ọmọ ogun bá mi nígbó mo dolú igbó
Ọmọ ogun bá mi lọ́dàn mo dèrò ọ̀dàn
Ọmọ ogun bá mi lórí ọ̀gún mo dolú esunsun.
Ọmọ gbélé-gbégbẹ̀ẹ́,
Ọmọ gbóko, gb'éjù-gbẹ́'gi
Igbó l'Olúkòyí ń gbé
Ǹwọn kì í gbé'gboro
Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí ọmọ ẹrù Ọfà
Ẹ̀ṣọ́ Ìkòyí kì í gb'ọfà lẹ́yìn
Ojú ni wọ́n fi í gbọta.
(Adéoyè, 1982: 79)

Àyọlò oríkì orílẹ̀ Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí òkè yìí fi hàn pé akíkanjú jagunjagun ni ìran yìí jẹ́ àti pé, wọn ò ní iṣẹ́ mìíràn ju ogun jíjà lọ. Ojú ogun tí Oníkòyí máa ń lọ kì í jẹ́ kí ó gbélé dáadáa. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà ni wọ́n máa ń gbénú igbó. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń kì wọ́n pé "gbélé-gbégbẹ̀ẹ́, ọmọ gbóko gbéjù-gbégbẹ̀ẹ́". Títí di òní ni Yorùbá sì tún gbàgbọ́ pé ẹ̀jẹ̀ ìran Oníkòyí sì tún wà lára àwọn Yorùbá tí ìran yìí bá ṣẹ̀ sílẹ̀, tí ó jẹ́ pé wọ́n máa ń láyà láti lè kojú ìjà. Àwọn àrọ́mọdọ́mọ ìran yìí sì máa ń láyà láti lè kojú ogun.

Bákan náà ni a tún rí àpẹẹrẹ iṣẹ́ ìran nínú oríkì ìran Olúòjé tí ó fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí akíkanjú jagunjagun. Àpẹẹrẹ nìyí ní ìsàlẹ̀ yìí:

Olú-òjé ọmọ Ẹ̀rín-ṣàko
Olú-òjé ọmọ Àfọbẹ́ké-jagun Ẹkọrọ
Ìhòòhò l'Olúòjé jagun ìgbànnì
(Adéoyè,1982: 63)

Àyọlò oríkì-orílẹ̀ ìran Olúòjé yìí fi ìran yìí hàn pé iṣẹ́ ogun jíjà ni iṣẹ́ wọn. Wọ́n jẹ́ akíkanjú, wọ́n láyà, wọ́n sì máa ń fi gbogbo ara jagun débi pé wọn kì í mọ ìgbà tí aṣọ yóò ya mọ́ wọn lára. Yàtọ̀ sí èyí, "ọ̀bẹ̀ké" tí ó túmọ̀ sí yèèpè kan tí ó máa ń hún ènìyàn lára ni ìran Olúòjé tún máa ń fẹ́ sínú afẹ́fẹ́ láti lè fi bá ọ̀tá wọn jà. Nígbà tí yèèpè yìí bá ń hún àwọn ọ̀tá lára, kò ní jẹ́ kí wọ́n rójú ráàyè tẹ̀síwájú nínú ìjà tító tí Olúòjé yóò fi lè rí wọn mú, tí yóò sì ṣẹ́gun. Yèrèpè yìí jẹ́ ọ̀kan lára ohun-èlò ìjà ogun tí wọ́n máa ń lò láti dojú ìjà kọ ọ̀tá lójú ogun. Èyí sì fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí ìran tí ó máa ń fọgbọ́n orí ja àjàṣẹ́gun.

Bákan náà, nínú oríkì ìran Àágberí, ó hàn gbangba pé iṣẹ́ ìṣègùn ni iṣẹ́ àwọn babańlá wọn. Àyọlò oríkì ìran yìí sì fi èyí hàn. Ẹ wo àpẹẹrẹ isàlẹ̀ yìí:

Ohun tií jẹ́'ni ó gbòde bàbá rẹ lọ
Iwọ akúápá
Ó mbẹ l'ájà bàbá rẹ
Iwọ akíndanidáni
Ó mbẹ l'ájà bàbá rẹ
Ọmọ afòjìgòdò gb'árúgbó-rè-gbẹ́
Lọ-rè-í-jó-oògùn-ìlàyà.
Alárúgbó-ó-parúgbó-ẹ̀-mọ́
O ó ṣ'orò baba rẹ lọ́la.
(Babalọlá, 1967: 54-55)

Àyọlò oríkì ìran Àágberí yìí fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí ìran oníṣègùn. Yorùbá mọ ìran yìí dunjúdunjú gẹ́gẹ́ bí ìran tí ó mọ ikú tí ó pa iṣu ìlò ewé àti oògùn bẹ́ẹ̀ sì tún ni pé wọ́n mọ ọ̀bẹ tí ó bẹ ẹ́ pẹ̀lú. Wọ́n sì máa ń lo agbára yìí láti lè jẹ gàba lórí àwọn ènìyàn láwùjọ débi pé wọ́n máa ń ṣe àfihàn èyí láti ṣẹ̀rù ba àwùjọ. Oríkì ìran Àágberí tẹ̀síwájú báyìí pé:

Àágberí ọ̀gá ọmọ Àjóórò
Ọmọ aṣewọ mọ́jú le koko
Ọmọ pèsè dè mí mò ń bọ̀

Kí n tó dé mo ti mésè náà jẹ[1]
(Ọlọ́jẹ́ẹ́dé Oyèdùntán, 2018)

Àgbékalẹ̀ àyọlò oríkì Àágberí òkè yìí fi ìran yìí hàn gẹ́gẹ́ ìran tí ó mọ oògùn iwọ àti oògùn ìkà. Ojú wọn máa ń le koko, wọn sì máa ń kó ìpayà bá ènìyàn nípa fífi oògùn dẹ̀rù bà wọ́n láwùjọ. Wọ́n tún máa ń ṣe oògùn líle tí a mọ̀ sí "iwọ" láti fi bá ènìyàn jà. Èyí sì jẹ́ kí àwùjọ ó bẹ̀rù wọn.

Àpẹẹrẹ iṣẹ́ ìran mìíràn ni a tún bá pàdé nínú oríkì ìran Arẹ̀ṣà, tí ó jẹ́ pé iṣẹ́ epo pupa fífọ̀ ni iṣẹ́ ìran wọn. Àyọlò oríkì ìran yìí sì fi èyí hàn:

Arẹ̀ṣà Òjèjé ojútì lalọ̀
Ọmọ Elépo rẹ́gún ojú omi
Arẹ̀ṣà dúdú lẹ̀gbọ́n, pupa l'àbúrò
Ojú l'ó fín dúdú tí ó w'ẹmọ fún pupa
Èdè òdí mọdẹ Ìrẹṣà
…
Ohun méje ni kò jẹ́ Ìrẹ̀ṣà ó gbélé ọkọ
Òní ng ó rè é ṣí ẹyìn, ọ̀la ng ó lọ ṣí èètán
Ọ̀tunla ng ó lọ rè é ya ọwọ̀
Ọjọ́ mẹ́rin òní ng ó lọ'gbó lọ kọ̀pẹ
Ọjọ́ márùn-ún ng ó lọ dín ìkẹ̀tẹ́
Ọjọ́ mẹ́fà ng ó lọ di ìgbágó
Ọjọ́ méje ng ó lọ ṣa èkùrọ́
Ọmọ kẹ̀kẹ́ etíjà mẹ́rìndínlógún
Bí mo bá ṣubú yẹ́kẹ́ ma tẹnu bepo

(Adéoyè, 1982: 74-79)

Àkíyèsí àyọlò inú oríkì ìran Arẹ̀ṣà yìí fi hàn pé iṣẹ́ epo pupa fífọ̀ niṣẹ́ wọn. Lára igi ọ̀pẹ ni a ti ń rí epo pupa. Ìran Arẹ̀ṣà yóò kọ ọ̀pẹ, wọn yóò ṣe ẹyìn ní ẹbu ìfọpo, wọn yóò sì yọ èkùrọ́, ihá, ògùnsọ̀ àti ìkẹ̀tẹ́ ara rẹ̀ kúrò títí tí yóò fi ku epo pupa nìkan. Títí di òní sì ni Yorùbá gbà pé ìran Arẹ̀ṣà ni ó máa ń ṣiṣẹ́ epo fífọ̀. Bí ìran yìí bá sì ń bínú, wọn ni á ní 'ẹ bu epo sí wọn lẹ́nu kí wọn mu, kí inú wọn lè baà rọ̀'. Ìdí ni pé ẹ̀rọ̀ ni epo pupa jẹ́.

**Èèwọ̀**

Èèwọ̀ ni àwọn nǹkan tí ẹnikẹ́ni kò gbọdọ̀ ṣe tó sì jẹ́ pé àtubọ̀tán burúkú n ló wà fún ẹni tí ó bá dẹ́jàá. Oríkì orílẹ̀ Yorùbá tún máa ń ṣe àfihàn èèwọ̀ ìdílé ìran tàbí orílẹ̀ kan. Èèwọ̀ yìí lè jẹ́ nípa ìwà ìkà tàbí ìyànjẹ kan tí babańlá ìran bẹ́ẹ̀ ti hù sí ẹrú babańlá wọn tàbí àlejò tí ó ń gbé ní ọ̀dọ̀ rẹ̀, tí irú ẹrú yìí tàbí àlejò bẹ́ẹ̀ sì ti fi wọ́n gégùn-ún látàrí ìyànjẹ yìí, pé bí wọn kò bá wọ irú

èèwọ̀ bẹ́ẹ̀ nǹkan kò ní dán mọ́rán fún wọn. Ọ̀pọ̀ èèwọ̀ wọ̀nyí ló máa ń jẹ́ ìjìyà fún àwọn ìyàwó tí irú ìran tàbí ìdílé yìí bá fẹ́. Nígbà mìíràn ẹ̀wẹ̀, ó lè jẹ́ oore tí ẹ̀dá Olódùmarè kan, bí ẹranko tàbí ẹyẹ igbó kan ti ṣe fún wọn saájú tàbí kí ó jẹ́ pé babańlá àwọn ìran bẹ́ẹ̀ yírapadà di irú ẹranko bẹ́ẹ̀. Irú èèwọ̀ yìí wá lè jẹ́ ìbọ̀wọ̀ fún irú ẹranko tí babańlá náà yíra padà sí nígbẹ̀yìn ayé rẹ̀ tàbí irú ẹranko/ẹyẹ bẹ́ẹ̀ ti ṣe wọ́n lóore síwájú. Bí àwọn ọmọ ìran wọ̀nyí bá jẹ èèwọ̀ yìí, a jẹ pé wọ́n fojú olóore wọn gúngi nìyẹn tàbí wọ́n jẹ babańlá wọn gégé bí ìgbàgbọ́ Yorùbá. Bí àpẹẹrẹ, ìran Oníkòyí kò gbọdọ̀ jẹ òkété àti ẹyẹ ẹ̀gà, ìran Olúòjé náà kì í jẹ ẹyẹ ẹ̀gà, Olúgbọ́n Àgbé kì í jẹ ajá, orílẹ̀ Ajíṣọlá kì í jẹ èse (ológìnní), ẹran ayè (àyìnrín, ẹlẹ́bọtọ̀, àgó (oríṣi eku kékeré kan tí ó máa ń ní ìlà lára, ìran Aláràn-án àti ìran Ewú Ìwínrín wọn kì í mu ẹmu àti ògùrọ̀, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ẹ jẹ́ kí á wo àpẹẹrẹ díẹ̀ lára èèwọ̀ wọ̀nyí:

Bí àpẹẹrẹ, oríkì orílẹ̀ Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí fi hàn pé àwọn ọmọ bíbí inú Oníkòyí tí ó jẹ́ jagunjagun kò gbọdọ̀ jẹ òkété. Ọmọ Ẹ̀ṣọ́ tàbí ìran Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí tí ó bá jẹ òkété, baba tó bí i lọ́mọ ló jẹ. Díẹ̀ nínú oríkì Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí fi èyí hàn pé:

Ìbílẹ̀ Ìkòyí, nwọn kì í jòkété
Ẹni tí ó bá jewú
Baba tó bí i lọ́mọ ló jẹ
Oníkòyí ló dóde Ọ̀yọ́-ilé
Ará Ìkòyí ẹ má ṣe jẹ̀gà
Ìbílẹ̀ Ìkòyí, ẹ má ṣe jòkété
Ọmọ Iyánbínlólú, ẹni tó b á jewú
Baba tó bí i lọ́mọ ló jẹ[2].

(Ayankọsọ Àyángúnjú, 2018)

Àyọlò oríkì Oníkòyí òkè yìí fi yé wa pé babańlá ìran Oníkòyí ló jagun títí tí ó sì fi yírapadà tí ó sì wọlẹ̀. Àwọn ọmọ Oníkòyí ló gbẹ́lẹ̀ kúṣẹ́kúṣẹ́ níbi tí Oníkòyí wọlẹ̀ sí, tí wọ́n sì bá òkété (ewú) pàdé níbẹ̀. Wọ́n sì gbàgbọ́ pé babańlá àwọn ni ó yírapadà tí ó sì ti di òkété. Ẹ̀wẹ̀, ó tún jẹ́ èèwọ̀ fún àwọn obìnrin Ìkòyí láti pe agbọ̀n ní agbọ̀n. Bí wọ́n bá ṣe bẹ́ẹ̀, a jẹ́ pé wọ́n tún ń pogun nìyẹn. Ìdí sì nìyí tí wọ́n fi máa ń ki ìran Ìkòyí báyìí pé:

Obìnrin Ìkòyí è é pagbọ̀n lágbọ̀n
Lọ́jọ́ ọ wọ́n bá pagbọ̀n lágbọ̀n
Ọpa gbuurugbu níí wọ́rú u wọn.

(Ọdẹàjò, 1992: 32)

Ìtàn sọ fún wa pé Agbọ̀n ni olórí aṣígun tí ó dojú kọ Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí lọ́jọ́sí. Ojú ogun le lọ́jọ́ yìí débi pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọmọ ogun Oníkòyí ló ṣòfò dànù. Bí obìnrin Ìkòyí bá wá tún dárúkọ Agbọ̀n a jẹ́ pé wọ́n tún ń mú orí rẹ̀ wú ni. Àyọlò ìsàlẹ̀ yìí jẹ́rìí sí èyí:

Ogun l'ó burú l'ẹ̀ṣá 'ò délé pé
Ogun l'ó burú l'ẹ̀ṣọ́ 'ò pe'ra wọn l'óókọ
Ẹ̀ṣọ́ Ìkòyí, ọmọ Agbọ̀n-l'ọ́nà
Ààdọ́jọ l'ẹ̀ṣọ́ n'ilé Igbọ́n
Alápó-ta-bíran l'ó kó wọn r'ojú ogun
Ogun náà l'ó pa wọ́n ni nwọn fi ku ààdọ́ta!
Ẹ̀rìn-dín sun'lé, ẹ̀rìn-dún sùn'de
…
Obìnrin Ìkòyí, nwọn kì í p'agbọn n'Íkòyí-ilé
N'íjọ́ tí nwọ́n bá p'agbọ̀n n'Íkòyí
Etí Ogun ni nwọ́n ń rán baba wa.

(Ògúnníran, 2007: 25)

Àyọlò oríkì orílẹ̀ Ìkòyí yìí fi ń yé wa pé bí obìnrin Oníkòyí bá pe agbọ̀n ní agbọ̀n a jẹ́ wí pé wọ́n tún ń rán Oníkòyí létí ogun nìyẹn.

Àpẹẹrẹ èèwọ̀ mìíràn ni a tún rí nínú oríkì ìran Olúòjé. Ìran Olúòjé kì í jẹ ẹyẹ-ẹ̀gà bákan náà nítorí pé oore ni ẹyẹ-ẹ̀ga ṣe fún Olúòjé náà. Bákan náà ni ìran Olúòjé kì í dá ọmọ wọn nígbààlẹ̀. Ìdí ni pé òòró gan-gan ni wọn ń bọ odò tí wọn ń bọ nÍpetu. Èèwọ̀ yìí ló sì ṣe àfihàn bí wọ́n ti ṣe máa ń ṣe ìtọ́jú ọmọ ìkókó wọn. Èèwọ̀ tí ìran Olúòjé ń wọ̀ yìí ló fà á tí wọ́n fi máa ń kì wọ́n báyìí pé:

Òòró gangan l'à á fohun odó f'ódó
Òòró làá bọ odò nÍpetu
Mo dúró mo mu ẹ̀kọ́ oyin
Mo dúró mo mu ẹ̀kọ àdò
Ìyá kò dá nyín l'ágbààlẹ̀ mu rí
Ríro gan-gan ni nwọ́n mú wọ́n
Ọmọ Ẹ̀rìnmòjé kì í jẹ̀gà
K'ẹni máa m'óròrẹ́ ṣiré
Tani yóò bá mi m'óròrẹ́ bọ̀ oko ?
Torí pé atúngun ni baba wọ́n fi ṣe.

(Adéoyè, 1982 : 65-66)

Àyọlò oríkì orílẹ̀ Olúòjé yìí jẹ́ kí á mọ̀ wí pé oore tí ẹyẹ-ẹ̀gà ṣe fún Olúòjé ni ó jẹ́ kí ó di ẹran èèwọ̀ fún gbogbo ọmọ Olúòjé. Oore tí ẹyẹ-ẹ̀gà yìí sì ṣe ni pé òun ni ó pariwo jí Olúòjé lójú oorun tí ó fi dìde nílẹ̀ láti lọ gbáradì de ogun tí kì bá ká a mọ́lé. Ní àfikún, ìran Olúòjé kì í dá ọmọ wọn ní ìgbálẹ̀. Òòró ni wọ́n máa ń fún ọmọ wọn lóúnjẹ. Ìdí ni pé òòró gan-gan ni wọ́n máa ń bọ òrìṣà odò tí ó jẹ́ òrìṣà tí wọn ń bọ ní Òjé nÍpetu.

Àpẹẹrẹ èèwọ̀ mìíràn ni a rí nínú oríkì ìran Alápà. Ìran Alápà kò gbọdọ̀ jẹ ẹran ejò. Ìran Alápà tí ó bá jẹ ẹran ejò, baba tó bí i ló jẹ. Àyọlò inú oríkì Alápà kan sì jẹ́rìí sí èyí :

Gbọ́lájókòó ọmọ erè lApà
Ọmọ Agbé-ńlá-ńlá-ọká ṣẹbọ
Ìran Alápà kan ò gbọdọ̀ jẹran ejò
Alápà ló dejò ló bá wọnú igbó lọ
N ló mú ìran Alápà tí ò fi gbọdọ̀ jejò
Alápà tó bá jejò baba tó bí i ló jẹ[3]

(Ọlọ́jẹ́ẹ́dé Oyèdùntán, 2018)

Ìtàn inú àyọlò oríkì Alápà òkè yìí fi hàn pé ọ̀kan lára ọmọ Alápà tí ìtàn ìwáṣẹ̀ kan yán fẹ́ẹ́rẹ́ pé ó jẹ́ ọmọ alè tí Alápà bí ló fọ́ ìkòkò àgbo tí Alápà fi ń máa ń yírapadà di ejò nígbà tí ó bá ń lọ sínú igbó láti lọ ṣe ọdẹ. Lọ́jọ́ kan tí Alápa àti òun àwọn ẹlẹ́gbẹ́ ọdẹ rè lọ sí oko ọdẹ ni ọmọ àlè yìí fọ́ ìkòkò àgbo yìí tí Alápà kò sì lè yírapadà di ènìyàn mọ́, tí ó sì mórí wọgbó lọ. Kí Alápà tó di pé ó wọnú igbó lọ yìí ló ti fi ìran rẹ̀ gégùn-ún pé ọmọ òun kankan kò gbọdọ̀ jẹ ẹran ejò mọ́ nítorí pé òun ni òun yírapadà di ejò, nítorí ìdí èyí ni ejò fi di ẹran èèwọ̀ fún wọn ní jíjẹ. Ìran Alápà tí ó bá jẹ ejò, ọ̀hun ni ó jẹ.

Àpẹẹrẹ èèwọ̀ mìíràn ni a tún rí nínú oríkì ìran Ewú-Ìwínrín àti ìran Olúfọ́n-adé. Àwọn ìran mẹ́jẹ̀ẹ̀jì ò gbọdọ̀ mẹmu àti ògùrọ̀. Èyí ni ó hàn nínú àpẹẹrẹ oríkì wọn ní ìsàlẹ̀ yìí:

Ewú Ìwínrín nilé bàbá mi tó bí mi lọ́mọ
Ọmọ ewú kékeré ma ranja létí ọya
Ewú Ìwínrín ni mi n ò gbọdọ̀ jẹ̀gbẹ̀sì
Òòṣà Ògìyán ló bí mi lọ́mọ
N ò gbọdọ̀ mògùrọ̀
Akèngbè ẹmu ò gbọdọ̀ wọ bòòṣà lÉjìgbò

Àti

Olúfọ́n-adé,
Mo níyọ̀ mo jàtẹ̀
Mo lépo nílé

Mo jẹlá ní funfun
Akèǹgbè ẹmu ò wọ bòòṣà
Ọmọ Olúfọ́n-adé.

Àyọlò inú oríkì ìran Ewú-Ìwínrín àti Olúfọ́n-adé fi hàn pé àwọn ìran yìí kò gbọdọ̀ mu ẹmu àti ògùrọ̀. Ohun tí ó fa èèwọ̀ yìí ni pé òrìṣà tí wọn ń bọ ní ìran wọn kì í mu ẹmu. Òrìṣà Ògìyán tí wọn ń bọ ní Èjìgbò àti Òrìṣà Olúfọ́n tí wọn ń bọ ní ìlú Ifọ́n náà là ń pè ní Ọbàtálá tàbí Òrìṣà Aláṣọ funfun. Ìtàn àtẹnudẹ́nu kan fi hàn pé ẹmu tí òrìṣà Ọbàtálá mu yó tí kò fi lè parí iṣẹ́ ìṣẹ̀dá ayé tí Olódùmarè gbé fún un ló jẹ́ kí ó sọ ẹmu di èèwọ̀ ní mímu. Gbogbo àwọn olùsìn rẹ̀ sì gbọdọ̀ pa èèwọ̀ yìí mọ́. Ìran Ewú-Ìwínrín tàbí ìran Olúfọ́n-adé tí ó bá tàpá sí èèwọ̀ yìí yóò ríjà Ògìyán tàbí Olúfọ́n. Ìran Ewú-Ìwúnrín kì í tún jẹ ẹ̀gbẹ̀sì bẹ́ẹ̀ sì ni pé wọn ò gbọdọ̀ fi ewé rẹ̀ ṣu ẹ̀kọ. Oore tí ewé ẹ̀gbẹ̀sì ṣe fún babaláwo tí Ewú-Ìwínrín fiyà jẹ ló jẹ́ kí ewé yìí di nǹkan ọ̀wọ̀ fún ìran Ewú-Ìwínrín títí di òní.

**Òrìṣà Ìran**

Ọ̀kan lára àkóónú oríkì orílẹ̀ tún ni àfihàn òrìṣà tí ìran kọ̀ọ̀kan ń sìn. Kò sí ìran kan ní ilẹ̀ Yorùbá tí kò ní òrìṣà tí wọn ń bọ tàbí sìn. Orúkọ òrìṣà bẹ́ẹ̀ sì máa ń hàn nínú oríkì wọn. Bí àpẹẹrẹ, Ọ̀rúnmìlà ni ìran Arẹ̀ṣà máa ń bọ, bẹ́ẹ̀ sì ni wọ́n tún máa ń sin òkú ẹṣin tí babańlá wọn ń gùn gẹ́gẹ́ bí ti òkú ènìyàn. Lẹ́yìn éyi, ó di kí wọn ó máa bọ ọ́. Ìdí nìyí tí díẹ̀ lára oríkì ìran Arẹ̀ṣà fi lọ báyìí :

Ọmọ bẹ́ṣin bá kú nwọn a gb'órí ẹṣin bọ
Bẹ́ẹ̀ ni ìrù ẹṣin l'òrìṣà Ìrẹṣà
B'ọ́dún bá dun n'íléÌrẹṣà'—Dú
Ọmọ kékeré a gbérù ẹṣin baba wọn
Nwọn a sì máa fi ṣe ikin bọ
Àwọn àgbààgbà tí mbẹ ní Ìrẹṣà-Dú
Nwọn a gbé ìrù ẹṣin bọ
Tèwetàgbà níí bọ ikin n'íléÌrẹṣà.

(Adéoyè, 1982 :74-78)

Àyọlò oríkì ìran Arẹ̀ṣà yìí fi hàn pé nígbà tí ẹṣin Arẹ̀ṣà kú, wọ́n tu ìrù ẹṣin yìí wọ́n sì sin ín bí òkú ènìyàn. Ìrù ẹṣin yìí ni àwọn ìran Arẹ̀ṣà máa ń gbé sí ìdí Ifá tí wọn máa ń bọ. Ifá tí ìran Arẹ̀ṣà máa bọ kò yẹ kí ó yà wá lẹ́nu nítorí pé láti ara ẹyin tí ìran Arẹ̀ṣà fi ń ṣe epo náà ni a ti ń rí èkùrọ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pẹ tí ó ń so ikin Ifá yàtọ̀ sí ọ̀pẹ tí a ti ń rí epo pupa.

Orísi àpẹẹrẹ àfihàn òrìṣà ìran mìíràn ni a tún rí nínú oríkì ìran Ìrèmògún. Bí àpẹẹrẹ, òrìṣà Ògún ni ìran Ìrèmògún máa ń sìn. Ìdí nìyí tí orúkọ òrìṣà tí wọ́n máa ń sìn yìí fi farahàn nínú oríkì wọn báyìí pé:

Ìrèmògún ọmọ Wọ̀nwọ̀
Ògún l'ó nilẹ̀ l'ó dá ìwọ̀
Bí o bá sí ìwọ̀ Ìrèmògún
Èmi la ó fi kẹja lọ́rùn l'áàrin agbalúgbú omi ?
Ọmọ aréyín-jajá-Ògún
Ìrèmògún ọmọ Abọ̀gúnyè.

(Babalọlá, 2001 : 54)

Àyọlò oríkì ìran Ìrèmògún yìí fi hàn pé iṣẹ́ Àgbẹ̀dẹ àti iṣẹ́ irin ríro ni iṣẹ́ ìran Ìrèmògún. Lára àwọn àbájáde iṣẹ́ irin-ríro ni a ti rí ìwọ̀ tí a fi ń pẹja lódò, ní èyí tí ó farahàn nínú oríkì yìí. Alágbẹ̀dẹ sì nìyí, òrìṣà Ògún ni wọ́n máa ń sìn.

Àpẹẹrẹ mìíràn ni a tún rí nínú oríkì ìran Ewú-Ìwínrín àti Olúfọ́n-adé tí ó jẹ́ pé òrìṣà Aláṣọ funfun tí a tún mọ̀ sí Òrìṣà Ọbàtálá, Òrìṣà Olúfọ́n ní ìlú Ifọ́n tàbí Òrìṣà Ògìyán ní ìlú Èjìgbò ni àwọn ìran méjèèjì yìí ń sìn. Èyí sì fara hàn nínú oríkì wọn báyìí pé :

Ìwínrín ni mí ma dalẹ̀ gbewùrà
Ìwínrín mọ dalẹ̀ ma gbìnkòkóró
Tí mo lónísukọ ó yàwáà jẹ
Ewú ńlá-ńlá ọmọ ajíbọwin
Òrìṣà Ògìyán ni wọ́n ń bọ ọ́ là lÉjìgbò[5].

(Ayankọsọ Àyángúnjú, 2018)

Àti

*Ọmọ Olúfọ́n-adé*
*Òròlú mo koyọ̀ mo jàtẹ́*
*Mo lépo nílé mo jẹlá ní funfun*
*Ọmọ ò-bá-bá-mi-dárè-ma-rè-ẹ́*
*Bóo bá ba mi dé Pópó ma fún ọ lẹ́gun mu*
*Aṣọ àlà ló gbó, kí ń máa wá onísẹ́ẹ́-ẹfun lọ*

*Òrìṣà Olúfọ́n l'ọmọ ṣẹ̀ mi kí nmú*
*Háhá kí nfi'gi há.*

(Gbàdàmọ́sí, 1961 : 8)

Àyọlò inú oríkì ìran Ìwínrín àti ti Olúfọ́n-adé ṣe àfihàn orúkọ òrìṣà tí wọn ń bọ ní ìran wọn. Òrìṣà Ògìyán ni ìran Ìwínrín ń bọ nígbà tí ìran Olúfọ́n-adé sì ń bọ òrìṣà Olúfọ́n tí a tún mọ̀ sí òrìṣà aláṣọ funfun.

Àpẹẹrẹ òrìṣà bíbọ mìíràn ni a tún rí nínú oríkì ìran Olúòjé. Òrìṣà tí ìran Olúòjé máa ń bọ ni òrìṣà Odò. Òrìṣà yìí ni a tún mọ̀ sí Yemọja. Èyí náà sì fara hàn nínú oríkì Olúòjé. Ẹ wo àyọlò yìí nínú oríkì Olúòjé :

Àwọn l'ọmọ olómi tééréte ìdí gbìngbìn
Tàwẹ̀dé l'omi tútù ẹsẹ̀ òkè
Tani enia tí yó tinú oòrùn dé
Tí yóò r'ómi tútù tíkò ní mu ?
Olú-òjé ọmọ Arọtí-wẹ̀-bí-òjò
Òòró gangan l'à á fohun odó f'ódó
Òòró gangan là á fódò f'ódò
Òòró là á bọ odò n'Ípetu.

(Adéoyè, 1982 : 64-67)

Èyí fi hàn pé òòró gangan ni wọ́n máa ń bọ òrìṣà odò (Yẹmọja) ní Ìpetu. Òrìṣà yìí ni wọ́n máa ń bọ láti lè wá ojú rere rẹ̀ nígbà tí àwọn obìnrin wọn bá ń ṣe àwáàrí.

Ẹ̀wẹ̀, àpẹẹrẹ mìíràn ni a tún rí nínú oríkì orílẹ̀ ìran Ẹ̀ṣà-Ògbín. Egúngún ni ìran wọn máa ń bọ ní tiwọn. Èyí sì farahàn nínú oríkì wọn náà. Ìtàn ìwáṣẹ̀ fi hàn pé ìran Ajíbógundé ni ó máa ń gbẹ́ igi tí a fi ń ṣe ère eégún, ìran Ọlọ́jọwọ̀n, Àré Ọ̀jé, Kújẹ́nrá ará Àgbóṣòkan tí wọ́n jẹ́ ìran kan náà ni ó máa ń rán ẹ̀kú eégún. Èyí fi hàn pé aṣọ eégún ni àwọn máa ń rán. Lásìkò ọdún ni Ẹ̀ṣà-Ògbín máa ń bá wọn ru ẹ̀kú eégún. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń sọ pé Ẹ̀ṣà-Ògbín ló kọ́kọ́ ru ẹ̀kú eégún. Wọ́n máa ń kì wọ́n báyìí pé :

Ológbojò l'ó kọ ru eégún
Lóòótọ́ Kújẹ́nrá ará Àgbóṣòkan l'ó l'aṣọ
Ẹ̀ṣà-Ògbín l'ó kọ́ ru àgọ́ l'ákọ̀ọ́kọ́ ọjọ́
Bọ́dún bá dé n'ílé Ọlọ́jọ̀wọ̀n
Ọmọ Kújẹ́nrá ará Àgbóṣòkan
Nwọn a yara kó'bì
Nwọn a bọ ẹ̀kú eégún
Bájọ̀dún bá kò n'ílé Ọlọ́jọwọ́n

Ọmọ Kújẹ́nrá ará Àgbóṣòkan
Nwọn a yára kóbì
Nwọn a bọ ẹ̀kú eégún
Àṣẹ̀hìnwáàṣẹ̀hìnbọ̀ l'Ológbojò d'ọ́dọ̀ wọn
L'ó bá kọ wọn pé nwọn ó máa ru'ṣọ.

(Ògúnníran, 2007 : 53-58)

Nígbà tí ìyàwó Ẹ̀ṣà-Ògbín dé odò nígbà tí ó lọ pọnmi ni ó bá eégún tí ó ti kú sójú omi. Èyí ni ó mú kí ó la agbè omi mọ́lẹ̀ tí eégún sì tají. Èyí ni igbá òkú tí wọn ń fọ́ mọ́lẹ̀ lóde Ògbín ilé. Mímú tí Ẹ̀ṣà-Ògbín mú òjò tí ó fẹ́ rọ̀ lọ́jọ́ tí ó fẹ́ fi eégún jó ló mú kí wọ́n máa pè é ní Ẹ̀ṣà-Ògbín ará Ògbojò. Báyìí ni Eégún ti ṣe di òrìṣà tí Ẹ̀ṣà-Ògbín ń bọ.

**Àléébù Ìwà**

Lára àkóónú oríkì orílẹ̀ náà ni ìtọ́kasí àléébù ìwà àwọn ìran kọ̀ọ̀kan ti máa ń farahàn. Oríkì orílẹ̀ máa ń ṣe àfihàn àléébù tí ó wà lára ìṣẹṣí àti ìhùwàsí àwọn ìdílé tàbí orílẹ̀ kọ̀ọ̀kan. Irú ìwà àléébù yìí lè jẹ́ ìwà ìjẹ̀gàba, ìwà ìkà, ìwà ìpànìyàn, ìwà àgbèrè ṣíṣe, ìwà agídí, ìjà jíjà, ìwà àbòsí, ìwà àìnàtán, ìwà àrékérekè, ìwà òjòwú, ìwà ìpánle, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Agídí**

Yorùbá gbà pé ìran Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí a máa lágídí púpọ̀, wọ́n máa ń fẹ́ obìnrin tí wọ́n bá jagun kó lójú ogun, kí wọ́n sì tún sọ wọ́n di aya. Ìdí nìyí tí wọn fi máa ń kì wọ́n pé :

Ọmọ ogun lọ́sàn-án olè lóru,
Olè tí ń kóṣu kélùbọ́ kọ́
Olè tí ń fẹ́bìnrin olóbìnrin ni[6]

Gbogbo bí wọ́n bá ti ń jagun bẹ́ẹ̀ náà ni wọn yóò máa kẹ́rú, kẹ́rù, kóbìnrin lójú ogun. Orílẹ̀ Òwu náà máa ń ránnú púpọ̀. Títí di òní sì ni Yorùbá gbà pé ìran Òwu máa ń dínú, bẹ́ẹ̀ ni wọn kì í sì mẹ́nu-kúrò lórí ọ̀rọ̀ bọ̀rọ̀. Wọ́n máa ń tẹnumọ́ ọ̀rọ̀ púpọ̀ jù. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń kì wọ́n ní :

*A bímọ l'Ówu, a lákọ mb'ábo?*
*Àtakọ àtabo, èwo ni yóò dàgbà*
*Tí yóò ṣe í-sìn nínú wọn?*
*Ẹ̀ránnú Òwu pọ̀*
*Àwíì-mẹ́nu-kúròni t'Òwu.*

(Babalọlá, 1966:141-142)

Àyọlò oríkì òkè yìí fi ìran Òwu hàn gẹ́gẹ́ bí òdínú tí wọ́n sì máa ń tẹnu mọ́rọ̀ púpọ̀ jù. Ńtorí náà, àwọn ènìyàn àwùjọ máa wòye pé gbogbo àwọn tí wọn kì í bá tètè mẹ́nu kúrò níbi ọ̀rọ̀ ṣe-ẹ́ṣe kí ó jẹ́ ìran Òwu.

**Ọrọ̀**

Ìran Olókùn-Ẹṣin ní ọlá àti ọrọ̀ púpọ̀, wọn sì máa ń fi ọrọ̀ àti ọlá wọn yangàn. Bí àpẹẹrẹ, oríkì orílẹ̀ ìran Olókùn-Ẹṣin lọ báyìí pé:

Olókùn-Ẹṣin kò bíni
Ká máa wọ̀là kiri.
(Àlàdé, 1963:25 nínú Ọlátúnjú, 1984:76)

Oríkì yìí fi ìran Olókùn-Ẹṣin hàn gẹ́gẹ́ bí ọlọ́rọ̀, tí ó sì fẹ́ràn fáàrí. Wọn kì í ṣẹ̀ṣẹ̀ tún máa ń garùn wọlá ọlọ́lá kiri mọ́. Yàtọ̀ sí èyí, ìran Olókùn-Ẹṣin tún máa ń fi ọrọ̀ tí wọ́n ní ṣe ìgbéraga láwùjọ. Ìdí nìyí tí wọn tún fi máa ń kì wọ́n báyìí pé:

Oníyàwó ń gbéyàwó
Ọmọ Olókùn-Ẹṣin ń daṣọ sán-án-yán bora
Olókùn-Ẹṣin ò mọ̀ pénú oníyàwó ò dùn
Olókùn-Ẹṣin ò mọ̀ pénú oníyàwó bàjẹ́.
(Babalọlá, 1976: 152)

Kókó-ọ̀rọ̀ tí a rí fàyọ nínú àyọlò oríkì Olókùn-Ẹṣin yìí fi hàn pé ìran yìí máa ń fi ọrọ̀ tàbí ọlá tí wọ́n ní ṣe ìgbéraga lójú àwọn ènìyàn àwùjọ. Nígbà tí oníyàwó ń ṣe ìgbéyàwó, tí ó sì ń ronú bí yóò ti ṣe rí owó ná, ìrònú èyí kò kan án rárá, aṣọ sányán olówó iyebíye ni Olókùn-Ẹṣin ń wọ̀ káàkiri ní tirẹ̀. Ìwà ìgbéraga ni èyí sì jẹ́ lójú ẹni tí ń gbéyàwó nítorí pé ọmọ Olókùn-Ẹṣin gan-an múra ju ẹni tí ó ń ṣe ìgbéyàwo lọ. Ọmọ Olókùn-Ẹṣin ò sì mọ̀ pé ìmúra òun yìí ń bí oníyàwó nínú, ní èyí tí ó yẹ kí ó múra ju gbogbo àwọn ẹni tí ó pè lóde lọ. Bí ìwà ìgbéraga ni èyí jẹ́, ó sì lè mú ìbànújẹ ọkàn bá irú ẹni tí ó ń wu ìwà bẹ́ẹ̀ sí.

**Owú**

Ìwà àléébù mìíràn ni a tún rí nínú oríkì ìran Òkò-Ìrèsé. Ìran yìí máa ń jowú púpọ̀. Lọ́wọ́ àwọn obìnrin wọn ni a ká owú jíjẹ yìí mọ́ púpọ̀. Owú jíjẹ yìí sì ti di bárakú fún àwọn obìnrin wọn. Èyí sì farahàn nínú oríkì wọn báyìí pé:

Ẹ̀nyin l'ọmọ-Ajowú-y'ọkọ-lẹ́nu
Jowújowú, kò lè jẹ ìkótí
Òjòwú ilé ẹnyin l'è j'abẹ
Òjòwú ni nyín, kò lè hun nyín mọ́
Kò lè hun yín mọ́,
Ìran baba nyín níí jowú.
(Adéoyè, 1982: 61)

Àyọlò oríkì Òkò-Ìrèsé òkè yìí fi wọ́n hàn gégé bí òjòwú lọ́ọ̀dẹ̀ ọkọ. Àyọlò ìsàlẹ̀ yìí sì tún jẹ́rìí sí èyí:

Òkò tẹ́ mi í lẹ̀ n ò bá torí ẹní wá
Ohun tí mo bá wá ju torí ẹní lọ.
Ìwà Òkò dára ni ò jẹ́ ń gbé méjì sílé.
Òkò dára Òkò wù mí
Owú jíjẹ wọn l'ó sú mi.
(Adéoyè, 1982: 64)

Ìwà owú jíjẹ obìnrin Òko-Ìrèsé kì í jẹ́ kí àlàáfíà wà láàrin ọkọ, ìyàwó àti orogún rẹ̀ lọ́ọ̀dẹ̀. Bí obìnrin bá sì ti ń jowú ara wọn, inú ọkọ wọn ò lè dùn. Lótìítọ́, ìran Òkò dàra, wọn sì lẹ́wà ṣùgbọ́n ìbẹ̀rù owú jíjẹ obìnrin Òkò méjì lọ̀dẹ̀dẹ̀ ọkọ kan náà ni kì í jẹ́ kí ọkùnrin mìíràn fẹ́ fẹ́ ju ìyàwó kan ṣoṣo lọ.

**Ọtí Mímu**

Lára ìwà àléébù ti ìran Olúòjé ní, ni ọtí mímu. Bí àpẹẹrẹ, ó hàn nínú oríkì ìran Olúòjé pé wọ́n máa ń mu ọtí púpọ̀:

Olúòjé ọmọ Arọ́tí-wẹ̀-bí-òjò
Lójó wọ́n bí mi
Ọtí ni wọ́n mu dáṣẹ̀ẹ́ mi.
(Adéoyè, 1982:65)

Bí ìran Olúòjé bá ṣẹ̀ṣẹ̀ bí ọmọ tuntun, wọn a máa da ọtí lé ọmọ náà lórí. Ní òde òní, àwọn ọmọ ìran Olúòjé kò fẹ́ kí wọn ó máa ki àwọn ní oríkì yìí mọ́. "Ọmọ arọ́lá wẹ̀ bí òjò" ni wọ́n yí oríkì yìí padà sí.

**Ìwà Ọ̀dọ́kọ**

Ìwà àléébù mìíràn ni a tún rí nínú oríkì ìran Ìrèmògún. Àwọn obìnrin ìran Ìrèmògún náà a máa dọ́kọ bẹ́ẹ̀ sì ni wọn a tún máa yan àlè. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń kì wọ́n báyìí pé:

Ìrèmògún ará Ìlágbẹ̀dẹ
Ọmọ adọ́kọ lórí ewé mọ́ jẹ́ yànrìn ó dà sí.
Ọmọ adọ́kọ níbi owó gbé ń so[7].

Àyọlò oríkì ìran Ìrèmògún fi hàn pé àwọn obìnrin wọn máa ń yan àlè púpọ̀. Nínú oko kòkó níbi tí ewé kòkó rẹ̀ sí ni àwọn ọkùnrin ti máa ń bá wọn láṣepọ̀. Owó kòkó ni àwọn ọkùnrin sì máa ń fi í fa ojú àwọn obìnrin náà mọ́ra, tí wọn fi máa ń bá wọn láṣepọ̀ nínú oko. Oríkì Ayérọ́nfẹ́ náà fi àwọn obìnrin wọn hàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀dọ́kọ. Ẹ tún wo àpẹẹrẹ yìí:

Ayérónfẹ́ iṣẹ́ ọkọ dídó niṣẹ́ baba wọn
Wọn kì í bá Èjìòkọ́mi níbi olè jíjà
Iṣẹ́ ọkọ dídó niṣẹ́ baba wọn[8].

Àyọlò yìí fi hàn pé ìran yìí kì í jalè, àmọ́ bó bá dibi iṣẹ́ okó dídó, ògá ni wọ́n.

**Ìwà Ọ̀falè**

Oríkì orílẹ̀ tún máa ń tọ́ka sí ìwà ṣìná àti àgbèrè ṣíṣe. Èyí sì wọ́pọ̀ lọ́wọ́ àwọn ìran kan. Ìwà àléébù náà ni èyí sì jẹ́ pẹ̀lú. Bí àpẹẹrẹ, ìran Ẹ̀rinmọ̀jé jẹ́ ìran òfalè. Wọn a sì máa bá obìnrin olóbìnrin/ ìyàwó oníyàwó láṣepọ̀. Ìdí nìyí tí díẹ̀ lára oríkì orílẹ̀ wọn fi lọ báyìí pé:

Èrìnmòjé ọmọ-agbé-sọnbọ-bọmọ nítan.
Ọmọ dónidóni abìdí mọ̀rànìnmọrani[9].

Sọnbọ tí a tọ́ka sí nínú oríkì yìí ni ó túmọ̀ sí okó (nǹkan ọmọkùnrin) nígbà tí itan sì túmọ̀ sí òbò (abẹ́ obìnrin). Àwọn ọkùnrin wọn sì mọ bí wọ́n ti ṣe máa ń bá obìnrin sùn kárakára.

Àpẹẹrẹ ìwà ọ̀falè mìíràn ni a tún rí nínú oríkì ìran Olúkòyí tí ó lọ báyìí pé:

Ẹ̀ṣọ́ Ìkòyí ọmọ ẹrù Ọfà
Ogun àjààwẹ̀yìn ló fi mú Ìkòyí wù mí
Ogun ojoojúmọ́ ló múlé baba wọn ṣú mi lọ.
Ènìyàn ò ní jàjààjà tó báyìí
Kó mọ́ folè jíjà díẹ̀ kún un
Olè tí ń kóṣu kélùbọ́ kọ́
Olè tí ń fẹ́bìnrin olóbìnrin ni[10]
(Ọlọ́jẹ̀ẹ́dé Oyèdúntán, 2018)

Àyọlò oríkì ìran Ẹ̀sọ́-Ìkòyí yìí fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí ọ̀falè. Ohun tí ó ń fa èyí ni pé lẹ́yìn ìgbà tí Ẹ̀sọ́-Ìkòyí bá ti jàjà-ṣẹ́gun tán lójú ogun tí ó bá lọ, á kó ẹrú, a kó ẹrù, yóò sì tún kó obìnrin pẹ̀lú. Ìwà ọ̀falè yìí sì tún farahàn nínú ìran Ìkòyí títí di òní. Ìdí ni pé wọ́n máa ń gba obìnrin olóbìnrin fi ṣaya. Agbára oògùn àti àyà tí wọ́n ní, ni wọ́n fi máa ń ṣe èyí.

Àpẹẹrẹ ìwà ọ̀falè mìíràn farahàn nínú oríkì ìran Olómù náà. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń ki ìran Olómù báyìí pé :

Ọmọ Olómù Apẹ̀rán
Ọmọ Ọlọ́rọ́ agogo
B'éwúrẹ bá sọnù l'ómù Apẹ̀rán
Ẹ má fi lọ̀ mí rárá
Ta ní bá nyín ṣẹgbẹ́ gbẹ́ran-gbẹ́ran ?
…
Àmọ́ b'óbìnrin bá l'ẹ́dan l'ọ́rùn
Tó tàdí rékeréke
Bá sọnù l'Ómù Apẹ̀rán
Ẹ má rán ẹlẹ́sẹ̀ wá pè mí, kó lè yá
Ẹni tí ó ba g'ẹṣin ni ẹ rán sí mi
Enia t'ó gb'árẹwà obìnrin kò fẹ́wọ́
Ẹni tí ó gb'ẹ́ran l'ó jalè, tí ó dìgárá.
(Adéoyè, 1982 : 93-94)

Àrífàyọ inú àyọlò oríkì ìran Olómù yìí fi hàn pé wọ́n máa ń jí obìnrin gbé tàbí gba ìyàwó oníyàwó. Èyí fi hàn pé wọ́n lójú kòkòrò obìnrin.

**Ẹbí**

Ìdí tí àwọn ìran kọ̀ọ̀kan fi bá ara wọn tan ni pé orírun kan náà ni wọ́n, àti pé ẹbí kan náà ni wọ́n jẹ́. Ibùgbé tí wọn ń gbé, ibi tí wọ́n ti fẹ́ ìyàwó, ìdílé ìyá, ìdílé bàbá kan náà ni gbogbo wọn ti ṣẹ̀. Ìbátan yìí máa ń jẹ́ kí á mọ̀ pé ìran kọ̀ọ̀kan ní ilẹ̀ Yorùbá tún máa ń bá ara wọn tan. Ohun tí ó ń fa ìbátan yìí ni pé bí a ti ń ki ènìyàn mọ́ ilé ìyá, bẹ́ẹ̀ náà ni à ń kì í mọ́ ilé baba. Bí a ti ń ki oríkì orílẹ̀ mọ́ ìlú bẹ́ẹ̀ náà ni a máa kì í mọ́ ìdílé. Bí àpẹẹrẹ, ìran Ọlọ́là tan mọ́ ìran Ìrènímògún Ará Ìlágbẹ̀dẹ tí ó jẹ́ pé òrìṣà Ògún jẹ́ òrìṣà tí wọ́n máa ń bọ, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìran Ọlọ́là tún máa ń bọ òrìṣà Ìyàké tí ó ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú òrìṣà Ọbàtálá. Ìran Oníkòyí tan mọ́ ìlú Oǹdó, bẹ́ẹ̀ ni ìran Ẹ̀ṣà-Ògbín náà tan mọ́ ìran Ọlọ́jọ̀wọ̀n àti Àre Ọ̀jẹ́. Ìran Elésèé Àyan tan mọ́ ìran Tápà. Ìran Ewú-Ìwínrín lÉjìgbò tan mọ́ Ìkirè ilé. Bí àpẹẹrẹ, ó hàn nínú oríkì Ewú-Ìwínrín báyìí pé:

Ewú pẹ̀lẹ́ ará Ìkirè
Ìwínrìn tí mo dálẹ̀ gbin ewùrà papọ
Ìwímrín tí mo dálẹ̀ gbin ìkókóró
Tí mo ní kóníṣukọ yà wá jẹ
Nílé baba tó bí yín lọ́mọ
Ewú bọ̀rọ́ ará Ìkirè
Ewú fọ̀nà hàn mí
Ewú ò jẹ́ fọ̀nà àbùjá ilé Ìkirè hanni
Ọmọ Ewú kékeré ma ranja létí Ọya[11].

(Ọlọ́jẹ̀ẹ̀dé Oyèdùntán, 20018)

Àyọlò oríkì Ewú-Ìwínrín òkè yìí fi àjọjóríkì papọ̀ Èjìgbò pẹ̀lú Ìkirè hàn. Èyí fi hàn pé wọn bá ara wọn tan.

Ìran Olúgbọ́n náà tan mọ́ ìran Olúwòó ọmọ odò ọbà. Iṣẹ́ jagunjagun tí wọn ń ṣe tún jẹ́ kí wọn ó tan mọ́ ìran Oníkòyí. Àyọlò oríkì wọn ní ìsàlẹ̀ yìí sì fi èyí hàn pe :

Bí wọ́n bá ń kì yín l'ọmọ olè l'ósì
Olúgbọ́n t'ó bí nyín kò gb'aṣọ, bẹ́ẹ̀ nikò gb'ẹ́wù
Nígbà tí Olúgbọ́n jagun tó m'óbìnrin l'ẹ́rú ni
Ni baba nyín bá sọ ẹrú t'ó mú d'aya
Ni nwọ́n fi ń kì yín lọ́mọ olè l'ósì
…
Irelúgbọ́n ọmọ ọba yaya ni pápá oko
Teleku níjù ni à á ki odò Ọbà.

(Adéoyè, 1982 : 90)

Ó hàn nínú oríkì Olúgbọ́n òkè yìí pe gẹ́gẹ́ bí Ẹ̀ṣọ́-Ìkòyí ti ṣe máa ń jagun tí wọ́n sì máa ń fi àwọn obìnrin tí wọ́n bá jagun kó lẹ́rú ṣaya bẹ́ẹ̀ náà ni ìran Olúgbọ́n náà máa ń ṣe. Bákan náà bí a bá wo ìran Elésèé Àgan, wọ́n tan mọ́ ìran Tápà nítorí pé orílẹ̀ kan náà ni wọ́n dìjọ ń gbé. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń kì wọ́n pé :

Ẹ̀nyin l'ẹbí Tápà l'Énpe n'ílé Ọya
Ọmọ òjò pa lami ọkà yọ dàràdàrà
…
Èniyàn yówù tí ó ki Ànàmú tí ò ki Tápà
Ibi níí bolúwarẹ̀ dé ibi tí ń lọ.

(Adéoyè, 1982 : 91-93)

Èyí fi hàn pé a lè ki ìran Elésèé Àgan mọ́ ìran Tápà.Bí a bá wo ìran Oníkòyí náà, wọ́n tan mọ́ ìran Olúgbọ́n. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń ki Oníkòyí báyìí pé :

A ki Igbọ́n má ki Olúkòyí, ara rẹ̀ ló tàn jẹ
Nítorí pé ìbí ni Olúkòyí gbà f'apákan
Bá àwọn ọmọ Olúgbọ́n tan.
(Adéoyè, 1982 : 82)

Ó hàn nínú oríkì òkè yìí pé ọmọlẹ́bí, ọmọ ìyá kan náà ni Olúgbọ́n àti Ẹṣọ́-Ìkòyí.

Àpẹẹrẹ ìbátan mìíràn ni a tún rí nínú oríkì ìran Àfọ̀njá tí a kì mọ́ ìlú Ìlọrin. A sì rí èyí nígbà tí wọ́n ń ki Ìlọrin báyìí pé :

Ìlọrin Àfọ̀njá ẹnu dùn juyọ̀
Ìlú tóbi báyìí kò léégún
Tó jẹ́ pé ẹṣin leégún wọn
Ọ̀kọ̀ lorò ibẹ̀.
Ọmọ afikálàmù dámọ lẹ́kun à ń ṣe kọ́ńdúkọ́ńdú
Ó bá Sàó tan lọ́tùn-ún,
Amọ́yọ̀ lórí ọmọ Akéwúgbẹní,
Ọmọ Afàdúà tọrẹ
Àrídòpó ọmọ Ègbìnrìn ọ̀tẹ̀
Wọ́n tan mọ́ Òpómúléró Mọja Àlekàn
Ogun ló sọ Àfọ̀njà di atẹ̀lú Ìlọrin[12].

Àyọlò àpẹẹrẹ oríkì Ìlọrin yìí jẹ́ kí á mọ̀ pé ìran Àfọ̀njá nílé Ìlọrin tan mọ́ ìran Sàó àti Amọ́yọ̀, bẹ́ẹ̀ sì ni ó tún tan mọ́ ìran Òpómúléró mọja àlekàn ní Ọ̀yọ́.

**Àpéjúwe Ìrísí àti Àbùdá Ènìyàn**

Oríkì orílẹ̀ tún máa ń ṣe àpèjúwe ìrísí àti àbùdá ènìyàn tàbí ìran kan. Bí àpẹẹrẹ, nínú oríkì ìran Ajíbógundé ni a ti mọ̀ pé gbogbo ọmọ tí a bá bí lọ́kùnrin ni wọ́n máa ń ṣígbọnlẹ̀, wọn a sì máa rẹwà, wuyì àti dùn-ún wò lójú. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń kì wọ́n báyìí pé :

Ọmọ Ẹlẹ́yọ́-àwújù
Ọkùnrin tàárà kanlẹ̀ ń sàlẹ̀ ọ̀wọ̀n.
(Babalọlá, 2001 : 130)

Àyọlò kékeré inú oríkì ìran Ajíbógundé yìí fi hàn pé àwọn ọmọkùnrin ìran Ajíbógundé máa ń dúró tọ́, wọn a sì máa wuyì lọ́kùnrin.

Àpẹẹrẹ ìrísí mìíràn ni a rí nínú ìran Ayérónfẹ́. Àwọn obìnrin ìran Ayérónfẹ́ máa ń lẹ́wà púpọ̀. Ẹwà yìí ló sì máa ń mú wọn ṣoge. Oge àti fáàrí wọn yìí ló sì máa ń sún wọn débi ìwà ọ̀dọ́kọ tí a máa ń ká mọ́ wọn lọ́wọ́. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń kì wọ́n báyìí:

Àṣẹ̀ṣẹ̀  s'oge ọ̀kọ̀mí bí ẹni tí kò ní gbó mọ́
B'ó dàgbà t'ó ní òun kò gbó
B'ó pẹ́ tító ojú a máa hunjọ

Mò ń lọ wá, mò mbọ̀ wá

L'ọmọ Ayérónfẹ́ fi b'ọkọ salọ

Ìgb`tí Ọ̀kọ̀mí bá fẹ́d'aya ẹlòmíràn

Ọmọ Ayérónfẹ́ a filé yá ẹ̀ tan ọkọ jẹ.

(Adéoyè, 2001: 97)

Àyọlò òkè yìí fi àwọn obìnrin ìran Ayérónfẹ́ hàn gẹ́gẹ́ bí onífáàrí àti ṣogeṣoge. Bákan náà ni oge tí wọ́n ń ṣe yìí ló máa ṣàkóbá fún wọn tí wọ́n fi máa ń kọ ọkọ àárọ̀ ọjọ́ wọn sílẹ̀ bá ọkọ mìíràn sálọ. Èyí fi hàn pé àwọn obìnrin ìran Ayérónfẹ́ kì í gbé ilé ọkọ. Ìran ọkọ-kan-ò-kún-kọ́bọ̀ọ̀dù ni àwọn ọmọbìnrin wọn ṣe. Àpẹẹrẹ àpèjúwe ìrísí àti àbùdá àwọn ìran tí a mọ̀ sí ìran Òko-Ìrèsé náà tún hàn nínú oríkì wọn. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń kì wọ́n báyìí pé :

Òkò Ìrèsé ọmọ ẹwù tó dìran
Ajíṣọlá o ọmọlẹwà
Òkò Ìrèsé ọmọ lẹwà ẹni.

*(Adeoye, 2001:97)*

Àyọlò òkè yìí fi hàn pé àwọn ọmọbìnrin ìran Òkò-Ìrèsé máa ń rẹwà púpọ̀. Gbogbo ìran ọmọbìnrin Ajíṣọlá tí ó bá pupa ló máa ń ṣe ṣìná tàbí dọ́kọ. Ìdí nìyí tí wọn fi ń kì wọ́n pé :

Ará Ìrèsé nwọ́n ní kí n má f'ọ́kọ pupa
Nwọ́n l'ọ́kọ dúdú sunwọ̀n l'óbìnrin
Nwọ́n ní pupa ṣẹ́wó j'ajá lọ.
(Adéoyè, 1982 : 63)

Èyí fi hàn pé dọ́kọdọ́kọ ni àwọn ọmọbìnrin ìran Òkò-Ìrèsé. Ẹwà tí wọ́n ní yìí náà ló sì ń mú wọn ṣe bẹ́ẹ̀. A fi ọmọbìnrin pupa ìran Òkò-Ìrèsé wé ajá nípa ìrísí, ìṣe àti ìhùwàsí nígbà tí takọ tabo ajá bá fẹ́ gun ara wọn.

Bákan náà ni ó tún hàn nínú oríkì ìran yìí pé wọn kì í ga púpọ̀. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń kì wọ́n báyìí pé :

**ONDO JOURNAL OF ARTS**
**Faculty of Arts**
**Adeyemi Federal University of Education, Ondo**
OPEN ACCESS https://ojaafued.com/index.php/ojall Volume 1, Number *1, 2025*

Kúkúrú Ìrèsé, nwọn jọ gígùn ahun
Rọ̀gbọ̀dọ̀ Ìrèsé jọ gígùn ejò
Kàkà kí nwọn ó gùn l'Ókò Ìrèsé
Nwọn a rí tẹ́rẹ́ bíi'gbá oko.
(Adéoyè, 1982 : 62-63)

Àyọlò òkè yìí fi hàn pé ìran Òkò Ìrèsé kì í ga, wọ́n máa ń tẹ́ẹ́rẹ́ ni nínú ìrísí wọn.

Àpẹẹrẹ ìrísí mìíràn ni a tún rí nínú oríkì ìran Ìrèmògún. Ìran Ìrèmògún a máa dọ̀tí. Wọn kò ní ìmọ́tótó. Ohun tí ó sì fa èyí ni pé iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ tí ó jẹ mọ́ ìlò èédú, iná àti èéfín ni iṣẹ́ wọn. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń kì wọ́n ní :

*Èèmọ̀ lẹ́yìn aṣÀpà, baba mi ń ṣe l'ẹ́yìn igi abèédú*
*N'Ílààgbẹ̀dẹ, baba wa dúdú ojú, ẹ dúdú ní ẹnu*
*Ẹ ṣàgbọ̀n ìsàlẹ̀ worìworì*
(Adéoyè, 1982 : 54)

Àyọlò òkè yìí jẹ́ kí á mọ̀ pé àwọn alágbẹ̀dẹ a máa dọ̀tí púpọ̀. Wọn kì í láfínjú. Iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ tí wọ́n ń ṣe náà ló máa ń mú wọn dọ̀tí bẹ́ẹ̀ nínú ìrísí wọn.

**Ìtàn Sísọ/ Ìyán-ọ̀rọ̀-fẹ́ẹ́rẹ́**

Itàn sísọ/ ìyán-ọ̀rọ̀-fẹ́ẹ́rẹ́ náà jẹ́ ọ̀kan lára àkóónú oríkì orílẹ̀ Yorùbá. Sàsà ni oríkì orílẹ̀ kan tí a kò ní bá ìtàn ìyán-ọ̀rọ̀-fẹ́ẹ́rẹ́ tí ó mẹ́nu ba ìṣẹ̀lẹ̀ kan fẹ́ẹ́rẹ́ níbẹ̀. Lọ́pọ̀ ìgbà, oríkì orílẹ̀ kì í sọ ìtàn náà lódindi, yíyán fẹ́ẹ́rẹ́ ni. Bí àpẹẹrẹ,' Ẹla Okò ò gbọdọ̀ jẹ ẹran ẹ̀gà'. Itàn gidi ló rọ̀ mọ́ èyí. Ìtàn bí ẹran ẹ̀gà ti ṣe di èèwọ̀ fún ìran Olúòjé ni akéwì yán fẹ́ẹ́rẹ́ níbí. Ìtàn tí a máa ń bá pàdé nínú oríkì orílẹ̀ yìí máa ń jẹ́ kí á gbà pé òtítọ́ máa ń farahàn nínú lítíréṣọ̀ alohùn Yorùbá ju ìtàn gidi lọ. Ìdí nìyí tí Aristotle fi sọ pé "poetry is truer than history" (Ewì alohùn máa ń fi òtítọ́ hàn ju ìtàn gidi lọ). Èyí sì rí bẹ́ẹ̀ nítorí pé lẹ́nu àwọn arọ́kin, àwọn onírárà, oníjààlá ọdẹ, apẹ̀ṣà, ẹlẹ́kún ìyàwó àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ni a ti máa ń gbọ́ ìtàn lọ́lọ́kan-ò-jọ̀kan nípa àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ti wáyé kọjá tí ó sì ṣáábà máa ń jẹ́ òtítọ́. Bí àpẹẹrẹ, ìtàn bí Ẹ̀ṣà-Ògbín ṣe di ológbojò tí ó ń ru ẹ̀kú eégún jẹ jáde nínú oríkì Ẹ̀ṣà-Ògbìn, ìtàn tí ó sọ nípa bí Alápà ti ṣe di ejò tó wọ́ wọnú igbó lọ hàn nínú oríkì ìran Alápà, ìdí tí ìran Oníkòyí kì í fi jẹ ẹran òkété hàn nínú oríkì Oníkòyí bàkan náà.

Ìlò "èmi", "mo", "a" àti "mi" nínú oríkì sì máa ń jẹ́rìí sí èyí lọ́pọ̀ ìgbà. Ẹ jẹ́ kí á wo àgbékalẹ̀ oríkì Ẹ̀ṣà-Ògbín yìí gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ :

Ẹ̀ṣà-Òbgín tí mo gbágò mo tàdí réke
Mo dúró rẹ́gí ní abẹ́ aṣọ
Mo mọ́wọ́ bẹbẹ mo fi r'agò lọ ìgbàlẹ̀

(Babalọlá, 1967 : 92)

Àyọlò oríkì Ológbìn-ín yìí fi hàn pé ìran Ẹ̀ṣà-Ògbín ni akéwì/apèṣà yìí, tí ó ti ru ẹ̀kú eégún rí, tí ó sì ń jó bí ìran Ẹ̀ṣà-Ògbín pẹ̀lú. Ìlò 'mo" ló sì fi èyí hàn. Bí apèṣà yìí ò tilẹ̀ sọ pé òun jẹ́ ọmọ ìran yẹn síbẹ̀ ó sọ ọ́ lásọyán pé òun náà kópa rí nínú ẹ̀kú egúngún rírù. Apèṣà tẹ̀síwájú pé :

A-kọ́kọ́ wa lọ Ọ̀yọ́ l'Áàfin
Igba eégún péré l'a ń mú lọ
A á lọ Ọ̀yọ́ ẹlẹ́ẹ̀kejì,
Igba eégún péré l'a mú lọ
A a lọ Ọ̀yọ́ ẹlẹ́ẹ̀kẹta
Igba eégún péré la mú lọ.

(Babalọlá, 1967 : 93)

Ijó tí Apèṣà sọ pé òun bá wọn jó yìí jẹ́ èyí tí ó rí gẹ́gẹ́ bí ìran Ẹ̀ṣà-Ògbín ti ṣe máa ń jó sí orin wọn. Àsọdùn ni èyí jẹ́ nínú àgbékalẹ̀ oríkì orílẹ̀ yìí .Ohun tí akéwì fẹ́ kí á mọ̀ ni pé ìran Ẹ̀ṣà-Ògbín ní egúngún púpọ̀. Èyí sì máa ń jẹ́ kí á gbà pé òtítọ́ wà nínú oríkì Yorùbá nítorí pé apèṣà máa ń so àwọn nǹkan tó ti ṣẹlẹ̀ sẹ́yìn mọ́ èyí tí ó ń ṣẹlẹ̀ lọ́wọ́lọ́wọ́. Gbogbo èyí ló sì máa ń jẹ yọ nínú oríkì orílẹ̀.

Àpẹẹrẹ oríṣìí iyán-ọ̀rọ̀-fẹ́ẹ́rẹ́ mìíràn ni a tún rí nínú oríkì ìran Oníkòyí. Ìtàn ìwáṣẹ̀ kékeré kan sọ pé ogun pa ìran Oníkòyí àti Olúgbọ́n pọ̀. Wọ́n pàdé ní Odò Ọbà. Ebì sí ń pa wọ́n, ni wọ́n fi lọ kó iṣu mẹ́fà tí wọ́n bá nídìí ọ̀gẹ̀dẹ̀ tí wọ́n sì sun ún jẹ. Olóko mú wọn lólè ṣùgbọ́n Olúgbọ́n kò lè sọ pé olè ni Oníkòyí tí àwọn dìjọ sun iṣu yìí jẹ, bẹ́ẹ̀ sì ni Oníkòyí náà kò lè ṣe bẹ́ẹ̀. Báyìí ni Olúgbọ́n ṣe sọ pé níbi tí Oníkòyí bá ń lọ àwọn ó dìjọ máa lọ ni. Ìdí sì nìyí tí wọ́n fi ń ki Oníkòyí àti Olúgbọ́n papọ̀ pé :

Béèyàn bá k'Olúgbọ́n
Tí ò k'Ìkòyí
Araa rẹ̀ ló ń tàn jẹ
Bẹ́ẹ̀ Olúgbọ́n àt'Ìkòyí
Wọn è é ṣèyekan
Ogun ló pa wọ́n pọ̀ níjọ́hun
Lọ́jọ́ wọ́n jàjààjà
Tí wọ́n pàdé lódò Ọbà
Ebi ń p'Olúgbọ́n
Ebi ń p'Àkòyí ogun Ìbírọ̀
Olúgbọ́n ló lọ abẹ́ ọ̀gẹ̀dẹ̀ àgbẹ̀
Ó bá múṣu mẹ́fà
Ni wọ́n bá sun'ṣu jẹ

**ONDO JOURNAL OF ARTS**
**Faculty of Arts**
**Adeyemi Federal University of Education, Ondo**
OPEN ACCESS https://ojaafued.com/index.php/ojall **Volume 1, Number *1, 2025***

Lolóko bá ká wọn mọ́bẹ̀
Ló bá mú wọn lólè.
(Ọdẹàjọ̀, 1992 : 321-32)

Àyọlò ìtàn yìí jẹ́ kí á mọ̀ pé jagunjagun ni ìran Olúòjé àti Olúgbọ́n. Wọn dìjọ máa ń lọ sí ojú ogun ni nítorí pé àwọn méjèèjì ló dìjọ jẹṣu oníṣu nígbà tí ebi ń pa wọ́n ní ogun tí wọ́n dìjọ jà ní odò Ọbà.

Àpẹẹrẹ ìtàn sísọ mìíràn ni a tún rí nínú oríkì Olóbùró. Ìtàn yìí ni ó sọ bí ó ti ṣe jẹ́ pé obìnrin ni ó pa Olóbùró. Àyọlò díẹ̀ nínú oríkì wọn sì jẹ́rìí sí èyí :

Agbada àkàrà haya Olóbùró gbé kaná
Ló bá rógun tó ṣú dẹdẹ bí aaró
Ó ní baálé wa
Ó rógun tó ṣú dẹdẹ bí aaró
Ó lọ́nà wo làwọn ó sáwọ̀
Olóbùró tọwọ́ bàgbo sàlà
Ó tọwọ́ bàgbo sòló
Ó ní ṣìgìdì tí kè é jajá
Ó bá dìde ó bógun lọ
…
Àwọn ṣìgìdì bógun lọ
Wọ́n sì ṣẹ́gun
Ó dọjọ́ ọ̀jọ̀ kan ọ̀ràn
Àwọn ogun wáá bá aya Olóbùró nínú ilé
Wọ́n fún un lówó
Ó tẹ́ ẹ lọ́rùn.
Wọ́n fún un láṣọ
Ó tẹ́ẹ lọ́rùn
Wọ́n lọ́nà wo làwọn lè gbà mọ́kọ ọ rẹ̀
Ó ní ṣìgìdì tí kì í jajá ẹ fún un lájá jẹ
Èyí tí kì í jàgbò ẹ fún un lágbò jẹ
…
Lọ́jọ́ ogun tún ṣú dẹdẹ bí aró
Olóbùró tọwọ́ bàgbo sàlà
Ó tọwọ́ bàgbo sòló
Ó pe gbogbo ṣìgìdì
Àwọn ṣìgìdì ò le è bógun lọ
Ohun la fi lóbìnrin ló p'Olóbùró.
(Ọdẹàjọ̀, 1992 : 29-30)

Ìsọníṣókí àyọlò ìtàn kékeré òkè yìí ni ó jẹ́ kí á mọ̀ wí pé èké àti ìwà ọ̀dàlẹ̀ tí aya Olóbùró hù sí i lọ́jọ́un ló jẹ́ kí ogun ó kó o lọ.

**Àpèjúwe Ibùgbé Ìran**

Oríkì orílẹ̀ Yorùbá tún máa ń ṣàpèjúwe ibùdó, agbègbè, àdúgbò tàbí ìlú tí ìran kan tẹ̀dó sí kí ó tó di pé ogun tú wọn ká. Ó sì tún máa ń ṣe àpèjúwe ìrísí wọn bákan náà. Bí àpẹẹrẹ, ìran Ọlọ́fà tẹ̀dó sí ilẹ̀ pápá/ọ̀dàn, ní ẹ̀báòkè. Níbi tí ọyẹ́ ti máa ń mú ni ìran Onígbẹ̀ẹ́tì tẹ̀dó sí, ilẹ̀ ẹgàn ni ìran Ìjẹ̀ṣà tẹ̀dó sí ní tiwọn nígbà tí ìran Tápà tẹ̀dó sí bèbè odò Ọya àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ẹ wo àpẹẹrẹ oríkì Ọlọ́fà yìí gẹ́gẹ́ bí àpẹẹrẹ :

Ọmọ a gán pápá kọ irinwó
Ọmọ a p'àjùbà k'ẹgbẹ̀fà
Ọmọ ò-wọ́-kuuru kọ ẹgbèrìndínlógún
Pápá l'a gán m'érin ní Ṣọ̀bẹ.

(Adéoyè, 1982 : 100)

Títẹ̀dó tí ìran Ìjẹ̀ṣà tẹ̀dó sí ilẹ̀ igbó ni wọ́n fi ń sọ pé: "Kín ni baba nyín ìbá wá dé'lẹ̀ bẹẹrẹ". Ogun tí ó ti ó sọ ìbí nù tí ó sì tún balé ará jẹ́ ló sọ ìran Ìjẹ̀ṣà lókò káàkiri ibi tí ìran wọn wà lóníí.

Bákan náà ni ìran Tápà tẹ̀dó sí etí odò Ọya tí à ń pè ní *River Niger* ní àríwá orílẹ̀-èdè Nàìjíríà. Ìdí nìyí tí a fi máa ń kì wọ́n ní :

Ọmọ Tápà l'Énpe
Alélú-Ọya.

Àyọlò oríkì òkè yìí jẹ́ kí á mọ̀ wí pé ní etí odò Ọya ni àwọn ìran Tápà tẹ̀dó sí bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ogun ti mú kí wọ́n ó fọ́n káàkiri orí ilẹ̀ Yorùbá lóde òní.

Agbègbè ibi tí ọyẹ́ ti máa ń mú ni ìran Onígbẹ̀ẹ́tì tẹ̀dó sí. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń kì wọ́n báyìí pé :

Ọmọ akọ́lé-d'ọyẹ́ ará Ìjí Ọ̀lẹ́lẹ́
…
Ọyẹ́ kì í p'ará Ìgbẹ́tì b'ọ́yẹ́ bá dé
Ọmọ Ọlọ́yẹ́-moyin
Ẹni tí a bí ọyẹ́ l'ọyẹ í pa.

(Adéoyè, 1982 : 69-70)

Àyọlò oríkì ìrin Onígbẹ̀ẹ́tì fi hàn pé lóòótọ́ ni ọyẹ́ máa ń mú púpọ̀ ní Ìgbẹ̀tì. Títí di òní sì ni èyí máa ń ṣẹlẹ̀ níbẹ̀.

**Àgbálọgbábọ̀**

Nínú iṣẹ́ yìí a ti wo ohun tí oríkì jẹ́, oríṣìíríṣìí oríkì tí ó wà àti àkóónú àwọn oríkì orílẹ̀ Yorùbá. A ṣe àkíyèsí pé oríkì máa ń jẹ mọ́ àwọn gbólóhùn tí ó máa ń sọ nípa oríyìn àti ìṣesí ọmọ ènìyàn. O Ìtọ́kasí onírúurú ìtàn àti ìtàn ìwáṣẹ̀, ìwúlò àti ìtumọ̀ wọn kúnnú oríkì orílẹ̀. Bí ìtàn geere kò tilẹ̀ sí nínú àgbékalẹ̀ rẹ̀ síbẹ̀ oríkì máa ń ṣe àfihàn àwọn akọni àti akíkanjú ẹ̀dá nínú ìran kọ̀ọ̀kan ní ilẹ̀ Yorùbá. Ìtàn àti ìtàn ìwáṣẹ̀ wọ̀nyí sì máa ń gbé àwọn orúkọ àti ìnagijẹ/àlàjẹ́ olóríkì jáde. Bí àpọ́npo, àwídùn tàbí àsọrégèé tí wulẹ̀ kí ó pọ̀ tó nínú oríkì, òtítọ́ máa ń farahàn níbẹ̀ nípa iṣẹ́-ọnà ayàwòrán-inú tí a fi gbé oríkì náà kalẹ̀, ìfira-ẹni-hàn nípa onírúurú ìṣẹ̀lẹ̀ àti ìrírí baba-ńlá olóríkì.

Nítorí náà a lè sọ pé oríkì àwọn nǹkan kọ̀ọ̀kan pàápàá ìran ni àkójọpọ̀ ohun tí Yorùbá mọ̀ láti ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ nípa ìṣẹ̀dálẹ̀ rẹ̀, ohun tíí ṣe ìwà àti ìṣe rẹ̀, àléébù rẹ̀, èèwọ̀ rẹ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Àkíyèsí fi hàn pé àwọn ọdẹ ní ìmọ̀ oríkì kíkì sodo sí lọ́dọ̀ jù lọ. Nítorí ìrírí wọn gẹ́gẹ́ bí àgbẹ̀, bí ẹ̀ṣọ́ ilẹ̀ Yorùbá, àti ipò wọn bí ọdẹ tí wọ́n jẹ́, yàtọ̀ sí mímọ ènìyàn, kò sí ẹranko, ewéko, tàbí ohun kan mìíràn tí wọn ò mọ ọ̀run rẹ̀. Àwọn apẹ̀ṣà, arọ́kin, àwọn obìnrin ilé àti asunrárà náà máa ń mọ oríkì í kì dáradára.

Ní ìparí, oríkì orílẹ̀ jẹ́ atọ́nà pàtàkì tí a lè tẹ̀lé láti mọ ibi tí irúwá-ògìrìwá tí à ń kò nínú àwọn ìlú àti ìletò Yorùbá ti ṣẹ̀, kì bàá ṣe òkun erémi, ikọ́ ni ìkọ́ í jẹ́, Ọlọ́fà ni Ọlọ́fà í jẹ́, bẹ́ẹ̀ni a kì í ki orílẹ̀ Òwu, Ìlọ̀kọ́, Oníkòyí, Arẹ̀ṣà, Ìrènímògún àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ yàtọ̀. Àkíyèsí fi hàn pé ìlò oríkì orílẹ̀ tí ń paré lọ díẹ̀díẹ̀ láwùjọ Yorùbá látàrí ẹ̀sìn ilẹ̀ òkèèrè tí a gbà. Ọ̀làjú náà ṣe àkóbá tirẹ̀. Àmọ́ sá, títí di òní ni ìwà àdámọ́ ìran kọ̀ọ̀kan tún ń fara hàn nínú ìṣesí wọn. Bákan naa, awon eya omoleyin-Jesu kan ko tii pa ilo oriki orile ti nigba ti won ba n ka itan igbesi aye oloogbe won to ti papòdà lasiko ayeye eto ìjáde oku ni soosi. Awon musulumi mìíran naa maa n se amulo oriki orile nigba ti won ba n se adura Fidau oku àgbà. Àwọn ọ̀jẹ̀wẹ́wẹ́ pohùn bí Àṣàbí Ọ̀jẹ̀ Afẹ́nápa, Àṣàbí Akéwì, Àmọ̀fẹ́ Oníkùn ewì àti àwọn mìíran tí ń fi oríkì orílẹ̀ ṣe iṣẹ́ ṣe nípa kí wọn ó máa lọ láti ojúlé dé ojúlé láti máa fi oríkì orílẹ̀ dábírà níbi tí àwọn ènìyàn bá ti ń ṣe ayẹyẹ ọjọ́ ìbí. Wọ́n sì ń rí owó rẹpẹtẹ gbà láti ibẹ̀. Oríkì tí wọn ń kì yìí ni wọ́n tì dè mọ́lẹ̀ sórí Ẹ̀rọ Ayélujára. Èyí fi hàn pé ẹ̀sìn ọmọlẹ́yìn-Jésù àti ẹ̀sìn mùsùlùmí kò tíì gba oriki orile kiki lọ́wọ́ iran Yorùbá tán pátápátá.

**Ìtọsẹ Ọ̀rọ̀**

1. Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò tí a ṣe láti ẹnu Àyánkọ́ṣọ̀ọ́ Àyángúnjú ní agbo ilé Alubàtá ní Ọ̀là-Èjìgbò, ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun ní 20/06/2018.
2. Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò tí a ṣe pẹ̀lú àpẹ̀ṣà Ọlọ́jẹ̀ẹ́dé Oyèdùntán ní agbo ilé Mérinmẹ́fọ̀n ní Ọ̀là-Èjìgbò, ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun ní 20/06/2018.
3. Ìwádìí tí a ṣe láti ọ̀dọ̀ apẹ̀ṣà Ọlọ́jẹ̀ẹ́dé Oyèdùntán ní agbo ilé Mérinmẹ́fọ̀n ní Ọ̀là-Èjìgbò, ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun ní 20/06/2018.
4. Sulaiman Ayílárá Àrẹ̀mú (a.k.a) Ajóbíewé (N.D). Àwo Ewì Oríkì Ilẹ̀ Yorùbá (Yorùbá Lineage Praises). Ìbàdàn : Moṣebọ́látán Global Links Ltd. Part 1 & 2.
5. Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò tí a ṣe láti ẹnu Àyánkọ́ṣọ̀ọ́ Àyángúnjú ní agbo ilé Alubàtá ní Ọ̀là-Èjìgbò, ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun ní 20/06/2018.
6. Sulaiman Ayílárá Àrẹ̀mú (a.k.a) Ajóbíewé (N.D). Àwo Ewì Oríkì Ilẹ̀ Yorùbá (Yorùbá Lineage Praises). Ìbàdàn : Moṣebọ́látán Global Links Ltd. Part 1 & 2.
7. Sulaiman Ayílárá Àrẹ̀mú (a.k.a) Ajóbíewé (N.D). Àwo Ewì Oríkì Ilẹ̀ Yorùbá (Yorùbá Lineage Praises). Ìbàdàn : Moṣebọ́látán Global Links Ltd. Part 1 & 2.
8. Sulaiman Ayílárá Àrẹ̀mú (a.k.a) Ajóbíewé (N.D). Àwo Ewì Oríkì Ilẹ̀ Yorùbá (Yorùbá Lineage Praises). Ìbàdàn : Moṣebọ́látán Global Links Ltd. Part 1 & 2.
9. Ìwádìí tí a ṣe láti ọ̀dọ̀ apẹ̀ṣà Ọlọ́jẹ̀ẹ́dé Oyèdùntán ní agbo ilé Mérinmẹ́fọ̀n ní Ọ̀là-Èjìgbò, ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun ní 20/06/2018.
10. Sulaiman Ayílárá Àrẹ̀mú (a.k.a) Ajóbíewé (N.D). Àwo Ewì Oríkì Ilẹ̀ Yorùbá (Yorùbá Lineage Praises). Ìbàdàn : Moṣebọ́látán Global Links Ltd. Part 1 & 2.
11. Ìfọ̀rọ̀wánilẹ́nuwò tí a ṣe pẹ̀lú àpẹ̀ṣà Ọlọ́jẹ̀ẹ́dé Oyèdùntán ní agbo ilé Mérinmẹ́fọ̀n ní Ọ̀là-Èjìgbò, ìpínlẹ̀ Ọ̀ṣun ní 20/06/2018.
12. Sulaiman Ayílárá Àrẹ̀mú (a.k.a) Ajóbíewé (N.D). Àwo Ewì Oríkì Ilẹ̀ Yorùbá (Yorùbá Lineage Praises). Ìbàdàn : Moṣebọ́látán Global Links Ltd. Part 1 & 2.

**Àwọn Ìwé Ìtọ́kasí**

Adéoyè, C.L. (1982). *Orúkọ Yorùbá.*Ìbàdàn: University Press Ltd.

Ademuyiwa, A.L. ((2022). "Ìtúpalẹ̀ Kókó-ọ̀rọ̀ àti Ìṣọwọ́lò-èdè Oríkì Ìlú Òkè-Ogùn". (A critical Analysis of Thematic and Stylistic Features in Oríkì-Ogùn ). An Unpublished PhD Thesis, Dept. of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Agbájé, B. (1989). "Iṣẹ́ Ìṣègùn". Nínú T.M. Ilésanmí (Olótùú) *Iṣẹ́ Ìṣẹ̀nbáyé*. Ilé-Ifẹ̀: Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University Press Ltd., o.i. 298-300.

Àjùwọ̀n, J. (2017). " Ìtúpalẹ̀ Àṣàyàn Oríkì Àwọn Akọnibìnrin àti Akọnibìnrin Yorùbá ní Ìwọ̀-Oòrùn Gúúsù Orílẹ̀-èdé Nàìjíríà". An Unpublished PhD Thesis, Dept. Of Linguistics and African Languages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Akínyẹmí, A. (1991). "Ìlò Oríkì Láwùjọ Ọ̀yọ́". Unpublished Ph.D. Thesis, Department of African Languages and Literatures, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ University, Ilé-Ifẹ̀.

Àmàó, A. (1989). *Àròfọ̀ Òkú Pípè*. Ìbàdàn: Longman Nig. Ltd.

Àrẹ̀rẹ́, A. (1979). *Àṣàyàn Oríkì*. Ìbàdàn: Uniẹersity Press.

Babalọlá, S.A. (1966). *The Content and Form of Yorùbá Ìjálá.* Oxford: Clarendon Press.

Babalọlá, S.A. (1967). *Àwọn Oríkì Orílẹ̀*. Glasgow: Collins.

Barber, K. (1979). "Oríkì ni Òkukù Town. Relationship between verbal and social structure". Ph.D. Thesis. Department of African Languages and Literatures, University of Ifẹ̀, Ilé-Ifẹ̀.

Dáramọ́lá, O. àtiu Jéjé, A. (1995). *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọn-Òjé Press & Book Ind. (Nig.) Ltd.

Gbàdàmọ́sí, B. (1961). *Oríkì.*Ìbàdàn: Mbari Publications.

Johnson, S. (1966). *The History of the Yorùbá.* London: CMS Bookshop.

Òjó, I. F. (2022). "Àfihàn Àbùdá Ẹ̀dá Òjó nínú Oríkì Yorùbá". *Aganjú: Jọ́nà Ẹ̀kọ́ Èdè àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá.* Ọ̀yọ́: Unique Concepts, pp.116-139.

Oyèláràn, O.O. (2014). "Oríkì". Ọlásọpẹ́ O. Oyèláràn àti Lawrence O. Adéwọlé (ol.), *Ìṣẹ̀nbáyé àti Ìlò Èdè Yorùbá*. Iléṣà: Elyon Publishers, o.i. 158-168.

Ọdẹàjò, L. (1992). *Àtúpalẹ̀ Lítíréṣọ̀ Àtẹnudẹ́nu*. Ìbàdàn: Fountain Publications.

Ọlátúnjí, O.O. (1984). *Features of Yorùbá Oral Poetry*. Ìbàdàn: University Press.

Rájí, S.M.; I. F. Òjó; J.O. Adéọlá, A.T. Táíwò, àti S.A. Àjùwọ̀n (2009). *Ọ̀kan-ò-jọ̀kan Ewì Alohùn Yorùbá*. Ìbàdàn: Alafas Nigeria Company.

Oyèwẹ̀sọ̀, M. O. (2025). "Fífi Tíọ́rì Ìọ̀ Àyíká Ṣàtúpalẹ̀ Kókó-ọ̀rọ̀ Ajẹmọ́-àyíká nínú Àṣàyàn Oríkì-orílẹ̀ Yorùbá". (An Eco-Critical Study of Eneiromental Issues in Selected Yorùbá Oríkì-Orílẹ̀). An Unpublished M. A. Thesis, Dept. of Linguistics and African Lanhuages, Ọbáfẹ́mi Awólọ́wọ̀ Unieersity, Ilé-Ifẹ̀.